# Isọdọmọ Apa Kẹta

Jeffersonville, Indiana, USA

Ọjọ Kejilelogun, Oṣu Karun, 1960

1 …Arakunrin Neville. Ẹ kaarọ ẹyin akẹkọ. Inu wa dun pupọ lati pada wa lẹẹkansi, ki a si ki yin ni orukọ to lagbara julọ ti Jesu Oluwa, mo gbagbọ pe ẹ ti ni ọsẹ to lagbara, to kun fun iyin ati Ibukun Ọlọrun.

Bi mo ṣe nbọ ni owurọ yii, mo pade ọmọkunrin kekere kan, o si fun mi ni patako aworan kan ti angẹli Olusọ kan ti nṣọ awọn ọmọde meji. Emi ko si mọ wipe, ọmọkunrin naa ni ọmọkunrin kekere ti ẹbi Daulton.

2 Ni ọsẹ diẹ sẹyin, ni nkan bi ọsẹ meji sẹyin, baba kan ti o jẹ Kristẹni beere fun ọmọbinrin rẹ ti o jẹ ọdọ laarin ọdun mẹtala ati mọkandinlogun ti ko tii di Kristẹni. Arakunrin naa duro si ori ila adura, Ẹmi Mimọ si wipe, "Mo fi ọmọ rẹ fun ọ". Ọmọbinrin naa si niyi lowurọ yii, ti a ti gbala, ti o ti ṣe itẹbọmi ni orukọ Jesu Oluwa, ti o joko sibi pẹpẹ, gẹgẹbi Ẹmi Mimọ ti sọ. Awọn ọmọ toku si joko kaakiri. Mo mọ wipe inu awọn ẹbi Daulton dun.

3 Wo obinrin kekere ti wọn gbadura fun ọmọ rẹ ni ọjọ Aiku to kọja, ti o ro wipe o nku lọ. Mo ri I wipe, ọmọ naa si wa laaye lowurọ yii, inu wa si dun pupọ fun iyẹn, arabinrin. Wọn ro wipe o ni aisan giri, oun ko si ni in. Nitori naa, a dupẹ pupọ lọwọ Ọlọrun.

4 A ri gbogbo awọn ọrẹ wa. Mo ranti ọkunrin yii ti o wa bami ni Chatauqua nigba kan. Mo jẹ ounjẹ owurọ pẹlu iwọ ati iyawo ati awọn ọmọ rẹ. Ni Middle town, mo maa n gbagbe orukọ yẹn, nitori naa ni mo ṣe maa n pe e ni Chatauqua. Bẹẹ ni, Sa.

Ọpọ awọn ọrẹ mi gidi lo wa nibi, Arakunrin Charlie Cox ati Arabinrin Nellie to wa nibẹ yẹn, ti ile wọn ti jẹ ile keji fun mi, wọn ko si yatọ si awọn ọmọ temi. Mo ma a nlọ sibẹ, nibẹ ni mo ti n lo pupọ akoko mi, lati farabalẹ. Arakunrin Charlie ni ọdẹ ọkẹrẹ to dara julọ ni Kentucky nigbati mo ba wa ni Indiana. Charlie, mo nsọ fun ọ bayi, mo sa fẹ pa awọn ẹja diẹ ni ki nto wa sibẹ yẹn. Mo nimọlara pe mo fẹ jẹ diẹ.

5 Arakunrin Parnell, Arnett lati South Carolina, ati ọpọlọpọ wọn lati orisirisi ibi ti wọn ti wa sibi lowurọ yii lati wa pẹlu wa.

Ṣe ẹ mo wipe, awa ko ni awọn ọmọ ijọ nibi yii. A saa ni idapọ mimọ pẹlu ara wa, nigbati Jesu Kristi Ọmọ Ọlọrun fọ wa mọ kuro ninu gbogbo aiṣododo.

6 Bayi, a nkọ ẹkọ agbayanu kan, ti o logo. A si ngbadun rẹ, o sa daju pe, emi ngbadun rẹ, mo si mọ pe gbogbo yin ni ẹ ngbadun rẹ pẹlu. Bi mo ba bẹrẹ si kọ nipa rẹ nigba miran, tabi ka nipa rẹ, emi yoo ka bi ẹsẹ meji, emi yoo si tẹle e ninu Iwe Mimọ ki n si to mọ ohun to ṣẹlẹ, mo ti tẹ lee lati Jẹnẹsisi de ifihan, ti a si nlọ sibẹ.

Mo si nwa akoko kan, ti a lee mu Iwe Heberu, ki a si kọ ọ. O dara, nigbati akoko ọkẹrẹ pipa ba de lati oṣu kẹjọ ọdun, titi ti asiko fun mi lati lọ si oke okun, ki a ma a kẹkọ ni alẹ kọọkan, ninu Iwe Heberu tabi Iwe Ekisodu. Bi Ọlọrun ṣe mu awọn eniyan Rẹ jade ni Ẹksodu, lati Ijipti - Ẹksodu kan, o jẹ apẹrẹ to lẹwa nipa imurasilẹ wa fun ijadelọ. Ah, ohun to lẹwa ni. Gbogbo Iwe Mimọ saa fi arakọra, o si jẹ itan nla kan.

7 Lowurọ yii, a si wa ninu Iwe Efesu. A fẹ kọ ori mẹta akọkọ ninu Iwe Efesu - tii ṣe Iwe Paulu si Ijọ Efesu, a ngbiyanju lati fi Ijọ si ipo rẹ. Ki a to lọ sinu rẹ, njẹ a lee fi iṣẹju kan tabi meji gba adura.

8 Oluwa, Ọlọrun wa, awa nbọ wa siwaju Rẹ bayi, bi a ṣe jẹ alaiyẹ to sibẹ, a mọ wipe irubọ ẹjẹ kan nduro, ti o nfọ wa mọ kuro ninu gbogbo aimọ, ti o si nmu wa wá siwaju Baba, lailabuku, ati lailabawọn. Ko si ohun kan ti a lee ṣe lati yẹ fun eleyi, sugbọn nitoripe Jesu ti ṣe eleyi fun wa, awa tẹriba pẹlu irẹlẹ si iwaju Rẹ ati orukọ Rẹ, a nbeere pe ki O ran Ẹmi Mimọ si aarin wa lowurọ yii. Bi emi kii si ti i ṣe ọmọwe ẹlẹkọ ẹsin, ti nko si mọ bi a ṣe ngbe Iwe Mimọ kalẹ, sugbọn ti mo saa ni inu didun ati ọkan imoore nipa Ẹmi Mimọ, bi O ṣe nsiṣẹ ninu mi; jẹ ki o bukun gbogbo wa ni apapọ, bi a ṣe nka ọrọ ti a kọ, ki o le di Iye ainpẹkun ninu wa. Ṣe bẹ fun wa, Baba. A beere rẹ ni Orukọ Jesu ati nitori Jesu. Amin.

9 Bayi, mo lee sọ eleyi ṣaaju, pe, bi a ba sọ ohunkohun nigbakigba ti o lodi - tabi ti o kuna nipa ẹkọ rẹ, mo gbẹkẹle Ẹmi Mimọ, pe ki o le jẹ eyi ti o dun to bẹẹ ti ko ni si ija rara, ki o lee jẹ nipa idapọ ti ifẹ, ki a si ri i bẹẹ.

Eyi si bẹrẹ pẹlu iwaasu kan lọjọ Aiku to kọja (mo gbagbọ pe owurọ ọjọ aiku ni) ti a pe ni "Ọba ti A kọsilẹ") Se a ri ẹniti o ti ri fọnran rẹ gba. Mo ro pe wọn ni fọnran rẹ, iwọ si lee ni in, bi o ba fẹ - Ọba Naa Ti A kọsilẹ.

10 O ku ọjọ diẹ si ti a o bẹrẹ ipade ni Middle town, Ohio. A fẹ ki gbogbo awọn ti o ti gba isinmi wọn si akoko naa ko rii daaju pe wọn pade wa nibẹ, nitoripe, a nreti akoko idapọ nla ni Middletown, Ohio. Ọmọwe Sullivan ni alaga igbimọ isọji naa. Alẹ ọjọ marun si ni. Emi ni yoo maa waasu gẹgẹbi Oniwaasu fun Agọ-ajọ ti awọn Ijọ to fọwọ kọwọ pẹlu awọn Ijọ miran, lẹyin naa ni awa yoo ṣe ipade tiwa, lati igba naa lọ. A ti ṣe eto rẹ titi di ọjọ kejila, Sugbọn a ni oye wipe, a lee tẹsiwaju fun ọsẹ kan si. O duro le bi Ẹmi Mimọ ba ṣe dari. Gbogbo wa ni a

fẹ ki a dari wa nipa ti Ẹmi. Ohun ti Ẹmi ba sọ pe ki a ṣe, nigba naa, ṣe e kiakia.

11 Ẹ si ranti pe, nigbati a ba nṣe igbọran si Ẹmi naa, ẹkọ nla kan ti a nilati kọ ni wipe, a ko gbọdọ kanju. Ṣe o rii, ṣe suuru, ki o si ni igbagbọ. Bi a ba ti beere ohunkohun lọwọ Ọlọrun, ranti pe Ọlọrun ndahun adura. O nṣe e ni akoko Tirẹ, ni ọna to dara ju, yoo si jẹ ki o ṣe wa nire. Bi iyẹn ko ba ri bẹẹ, nigba naa, kin ni a nṣe nibi lowurọ yii? Kin ni a n jẹwọ Kristi fun? Bi eyi ki I ba iṣe Ọrọ Ọlọrun, nigba naa, kii ṣe otitọ, a ṣe wipe, awa ni o jẹ otoṣi julọ ninu gbogbo eniyan.

Inu mi dun lati wa ni isọkan pẹlu ọpọlọpọ nibi, lati mọ wipe, eyi ni Ọrọ Ọlọrun ti ko lee kuna. Nigba naa, gbogbo rẹ ni o jẹ otitọ, ọrọ kọọkan ninu rẹ, gbolohun kọọkan rẹ, otitọ ni. Nipa oore-ọfẹ Ọlọrun, mo ti ni anfaani lati ri ilẹ naa ti a o lọ si lọjọkan.

12 Awọn eniyan ko mọ aarẹ ọkan ti o maa ntẹle iru iṣẹ iriju iwaasu bi eleyi. Lana, ọkan mi poruru pupọ, mo si sọ fun Iyawo mi pe, “Iba ṣeeṣe fun mi lati sa a kọja lọ”

Obinrin naa wipe, “Kin ni idi ti o fi sọ iyẹn, Bill?”

Mo wipe, “Ah, mo ni idaamu ati awọn nkan bẹẹ nihin.”

O si dabi ẹni pe, Ẹmi Mimọ wipe, “Ṣe iwọ ngbiyanju lati sa fun wọn ni? Se iwọ fẹ yẹba fun wọn?” Ṣe o rii?

Mo wipe, “Rara, sa a jẹ ki n dide niwaju gbogbo wọn ki n si doju kọ ọ.” Ṣe o rii?

Ibi ti a nlọ dara pupọ ju ibi lọ, nitootọ, mo sọ eyi nipa iriri, pe nigbati aye yi ba kọja, a nwọ ilẹ kan to dara ju ohunkohun ti ẹnikẹni lee ro lọ. Bi alejo kan ba si wa nibi, mo gbẹkẹle Ọlọrun wipe, iwọ ko ni ka mi si agbawere-mẹsin. Ohun ti mo fẹ ni pe, ki njẹ olotitọ, ki n si sọ otitọ. Ire kin ni yoo ṣe fun mi lati sọ ohun kan to jẹ irọ nigbati a ni ohun pupọ lati sọ ti o jẹ otitọ? Kin ni idi ti a o fi sọ ohun kan to kuna nipa rẹ? Ṣe o rii? Otitọ saa ni.

13 O wa yemi bayi, mo gbagbọ pe Paulu ni a gba soke si ọrun kẹta, o si ri awọn ohun ti ko yẹ ki o sọ. Lọjọ kan, o wipe, “Oju ko tii ri, eti ko tii gbọ ri, bẹẹ ni ko tii wọnu ọkan eniyan ri, awọn ohun ti Ọlọrun ti pese pamọ de awọn ti o fẹ Ẹ”.

Ah, awa ngbe inu koto ti a ndalẹ si, koju bẹẹ lọ. A ngbe ninu koto ti a da idọti si, ti o njo ti o kun fun eefin lati inu ẹgbin. Bi a ko tilẹ jẹ alabapin rẹ, sibẹ, a ngbe ninu rẹ, nibiti eefin ti nwa lati inu ẹgbin ti ẹṣẹ. Ohun ti o run buburu, to lee mu eniyan bi ti mo lee ronu nipa rẹ ni koto idọtin ilu kan to njo. Ṣe iwọ ti kọja nibi ọkan ri? Oorun buburu ti o buru jai ti nti inu eefin naa wa, nibiti oriṣiriṣi idọtin ati ẹgbin ti njo yẹn, ti iwọ ba si gboorun rẹ, yoo sa gbe ọ ni eebi ni.

14 Mo ranti igba ti mo nilati lọ si New Albany, nisalẹ ẹgbẹ opopo kejidinlogun, nibiti koto akitan ma a nwa tẹlẹ yẹn. Mo nilati gba owo ina nibẹ ki n si ka ẹrọ mọnamọna wọn. Mo si maa nkorira ọjọ ti mo nilati lọ sibẹ - iyẹn ni opopo kejindinlogun - nitoripe, oorun rẹ ti buru ju. Sibẹ, ninu ibẹ ni oku eku, ati ti aja ati ohun gbogbo ti njo, ti eefin rẹ si njade wa.

Bayi, ohun ti a lee fi aye yi we niyẹn, ti a ba fi we ọrun. Ohun to dara julọ laye yii, o sa jẹ koto ẹgbin ẹṣẹ ati oorun nibi gbogbo bi a ba wo o nipa ti Ẹmi. Sugbọn ibiti afẹfẹ ti nfẹ laisi idibajẹ ti o kun fun ifẹ, alaafia, ayọ, ati Iye ainipẹkun, nikọja odo naa! Sugbọn a wa loju ogun, nitori naa, ẹ maṣe jẹ ki a dawọ ogun duro, ki a wipe, “Ẹ jẹ ki a yara tete lọ sile”. Jẹ ki a mu gbogbo ẹniti a lee mu wa pẹlu wa. Bẹẹ ni.

15 Idi ti a fi nkọ ẹkọ yii nipe, ki a le fẹsẹ awọn to ti gbagbọ mulẹ ninu ilẹ naa. Idi ti a fi nkọ ekọ yii ninu iwe Efesu ni ki a fi Ijọ si ibiti yoo ti duro patapata si ipo rẹ ninu Kristi, o jẹ apẹẹrẹ iwe Joshua ti majẹmu Laelae nibiti Joshua ti pin ilẹ naa (A gbọ ọ ni ọjọ Aiku ti o kọja) fun olukuluku eniyan, ati iran nipa imisi.

Bi Mose ṣe mu awọn eniyan naa jade kuro ni Ijipti (nibiti wọn ti njẹ alubọsa ati ewebẹ), o fun wọn ni ibikan ti Ọlọrun ti ṣeleri fun wọn ni Irinwo ọdun ṣaaju, pe Oun yoo mu wọn wa si ilẹ kan ti o dara, ti o nsan fun wara ati fun oyin. Mose si mu awọn ọmọ Israẹli de ààlà ilẹ naa, sugbọn ko mu wọn wọ inu rẹ.

Jesu pẹlu ṣeleri fun awọn eniyan ti ẹmi lati ibẹrẹ, lati fun wọn ni ileri ti Ẹmi Mimọ, Jesu si mu wa de ati wọ ileri naa. Sugbọn Ẹmi Mimọ wa, gẹgẹbi Joshua, lati gba isakoso, lati dari, lati tọni sọna, ati lati gba ilẹ naa, lati kun ijọ.

16 Nibiyi ni awọn eniyan ti lero wipe, mo yaju, tabi mo n ṣe ainaani, tabi aika awọn ara si. Emi ko ṣe bẹẹ! Ki Ọlọrun ṣe idajọ mi, emi ko ṣe bẹẹ. Emi saa n gbiyanju lati tọka si ohun kan ti o jẹ otitọ. A ti yan awọn adari ti wọn jẹ eniyan ni ipo idari Ẹmi Mimọ. A ti ni awọn adari nipa ijọ-to-fẹko-adamọ-rọpo-Ọrọ Ọlọrun, gẹgẹbi Methodisti, Baptisti, Piresibiteria, Lutheria, Ijọ Kristi, Pẹntikọsita ati awọn Ijọ ẹlẹkọ adamọ ti o ku, ti wọn fi Ijọ

to-feniyan-sadari-dipo-Ẹmi Mimọ ṣe apẹẹrẹ, a si tẹle iyẹn.

Ko si ibikan ninu Bibeli ti a ti nilati ṣe iyẹn. Ko si Iwe Mimọ kan ti o sọ pe ki a ṣe Ijọ-to-feniyan-sadari. Nigba gbogbo ni Bibeli tako iyẹn. Ko fẹ ki a ṣe gẹgẹbi aye ti nṣe. O fẹ ki a jẹ eniyan ọtọ ti a ya sọtọ.

Emi ko sọ wipe ki a ṣe were, tabi ọ̀dẹ̀. Sugbọn ki a jẹ awọn eniyan ti a yasọtọ, ti a pe jade, orilẹ-ede mimọ, ti ngbe igbe aye ti ko ni abuku, ti a nwu iwa gẹgẹ bii Tirẹ, ti O nsisẹ ninu wa, nitori pe awa ni isẹ ọwọ Rẹ, ti a da ninu Jesu Kristi si iṣẹ rere gbogbo.

17 Ọpọlọpọ yin ni ko si nibi ni alẹ Ọjọru to kọja, sugbọn a de ẹsẹ karun: “Si isọdọmọ…” tabi fifi awọn eniyan sipo.

Bi Ọlọrun ṣe n lakaka lati fi awọn eniyan sipo… Nigbati Ọlọrun ba si fi ẹnikan sipo kan, gbogbo ijọ yoo fẹ dabi ẹni naa, wọn fẹ ni ohun kan naa, ki wọn si ṣe ohun kan naa. A da wa yatọ si ẹnikeji. A yatọ sira wa, a ni iwa ẹda to yatọ si ti ẹlomiran, a si fiwa sipo to yatọ sira - a fun olukuluku ni iṣẹ ti o yatọ lati ṣe. Boya ẹnikan fun iru iṣẹ kan ati ẹlomiran fun isẹ ti o tobi. Mo ro pe Dafidi ni tabi ọkan ninu awọn wolii ti o wipe. “O wu mi ki n jẹ ẹní-ìnùsẹ̀ ninu ile Ọlọrun, ju ki ngbe inu agọ kan pẹlu eniyan buburu.”

18 Bayi, a o duro diẹ lori isọdọmọ, ẹsẹ ikarun, a o si gbiyanju lati lọ jinlẹ bi a ba ṣe le e ṣe to lori rẹ. Sugbọn ranti koko ọrọ naa bayi, o duro patapata lori ifini-sipo. Ẹni melo ni o ye? Jẹ ki a sọ ọ papọ bayi (Ipejọpọ nsọ tẹle Arakunrin Branham): Fifi ara Jesu Kristi si ipo ninu Kristi, nibiti Ẹmi Mimọ ti n dari wa. Ohun niyẹn, o ti ye wa bayi. Fifi wa sipo - iwe Efesu nilati ṣe iyẹn.

19 Kiyesi Olukọni agba yii - Paulu. Oun kinni ti o ṣe nipe, o kọkọ yọ gbogbo ero wipe wọn lee ṣubu, ki wọn si ṣegbe danu. O yọọ danu wipe, o ṣeeṣe ki ojulowo Kristẹni ti a ti tunbi loni, ki o tun di ọla ki o ṣubu, ki Ọlọrun si daa lẹbi, lẹyin naa ki o tun pada wa. Radarada ni iyẹn! A ko kọ iwe yii fun ipolongo Ihinrere. Emi kii sọ eleyi ni ita, ninu ipade ipolongo Ihinrere. Mo ma a nmu eyi wa fun ijọ nitoripe Paulu kọwe naa si awọn eniyan mimọ, awọn ti a ti pe, ti a pamọ, ti a ti kun fun Ẹmi Mimọ, ti a si yasọtọ ninu Ẹmi Mimọ, ti wọn ti wa ni ilẹ Kenaani. O gbiyanju lati sọ fun wọn pe, ṣaaju, ẹ mu ero naa kuro ni ọkan yin wipe, ẹ o ṣegbe, tabi ibẹru kankan bẹẹ. Mase bẹru kankan, nitori o ngbiyanju lati sọ ipo rẹ, ati ẹniti iwọ jẹ, ati ọna ti ẹ fi duro.

20 Bayi, o ṣeeṣe ki iwọ ṣe ohun ti o kuna, nigba gbogbo ti iwọ ba si ṣe ohun to kuna, iwọ yoo jẹ iya rẹ! Bẹẹ ni, iwọ yoo ka ohun ti iwọ ba gbin! Sugbọn iyẹn ko ni ohun kan iṣe pẹlu igbala rẹ. Nigbati a bi ọ pẹlu Ẹmi Ọlọrun, iwọ ti ni Iye ainipẹkun, iwọ ko si lee ku, gẹgẹbi Ọlọrun ko ṣe le e ku. Iwọ jẹ ipa kan ninu Ọlọrun, ọmọkunrin Ọlọrun ni iwọ iṣe.

A bi mi gẹgẹbi Branham kan, Iwọ le pe mi ni orukọ miran. Orukọ miran ti iwọ pe mi ko yi mi pada - Branham ni mo si jẹ sibẹ. A bi mi gẹgẹbi Branham, emi yoo jẹ Branham titi. Lọjọ kan, ara mi le e di palapala, nipa arun arun-mọ-lee-gun, tabi nipa ijamba ọkọ kan, ki ara mi si wo, tobẹẹ ti yoo ri bi ẹranko kan. Sugbọn, Branham ni emi yoo jẹ sibẹ. Nitori kin ni? Ẹjẹ Branham ni o wa ninu mi.

21 Ohun ti iwọ jẹ niyẹn. Niwọn igbati Ọlọrun si ti ṣe ọ ni ọmọ Rẹ. Ranti bayi pe, emi ko sọrọ nipa awọn ti ko si ninu Kristi; mo nsọrọ nipa awọn to wa ninu Kristi. Bawo ni a ṣe nwọ inu Kristi? Nipa Ẹmi kan. Eyi jasi. “Nipa Ẹmi Mimọ kan ni a baptisti wa sinu ara kan.” Bawo ni a ṣe nwọle? Ṣe nipa itẹbọmi kan ni? Emi tako ẹyin Baptisti ati Church of Christ, ki i ṣe nipa itẹbọmi rara! Kọrinti kinni, ori kejila wipe, Nipa Ẹmi kan (Ẹmi Mimọ) ni a mu wa bọ sinu ara naa, a si wa ninu aabo, gẹgẹbi ara naa ti wa ni ipamọ. Ọlọrun ṣeleri rẹ.

22 Bawo ni Ọlọrun ṣe lee da Kristi lẹjọ lẹẹkan si nigba ti O ti lọ si Kalfari? O lọ si Gọlgọta, a lu u, a pa A lara. Oun ko si le e wosan, Oun ko tilẹ lee sọ ọrọ kankan. Nitori kin ni? O gbe gbogbo ẹṣẹ aye le ori Rẹ. Kii ṣe wipe Oun jẹ ẹlẹṣẹ, sugbọn a sọ Ọ di ẹṣẹ nitori iwọ ati emi. Gbogbo ẹṣẹ aye lati Adamu titi di bibọ Rẹ ni o wa lejika Rẹ. Ọlọrun ko si fi iya jẹ Ọmọ Rẹ. Ọlọrun fi iya jẹ ẹṣẹ. Ṣe o ri bi ẹṣẹ ti buru to? Ọlọrun nṣe etutu fun ẹṣẹ. Ọlọrun la ọna abayọ fun gbogbo awọn ti o ti mọ nipa imọtẹlẹ pe yoo wa. A o de inu eyi lẹyin iṣẹju diẹ si.

23 Nitori naa bayi, “Nipa Ẹmi kan ni a baptisti wa sinu ara yẹn, ara kan, tii ṣe ”Kristi“ a si wa ni ipamọ titi lae. Bayi, ibi yii ni o dabi ẹnipe o le diẹ; paa paa, fun awọn ara ijọ Arminia, ti wọn ro wipe, wọn nilati ṣe ohun kan lati lee yẹ funra wọn, tabi ohun akayẹ kan. Bawo ni o ṣe lee jẹ nipa ohun meji papọ nigba kan naa? O nilati jẹ nipa oore-ọfẹ tabi nipa iṣẹ, ọkan ni ninu meji yii. Ko le jẹ nipa mejeeji, wọn lodi si ara wọn, O nilati jẹ ọkan ṣoṣo ninu wọn.

24 Ni temi, emi ko ri ohun miran yatọ si oore-ọfẹ Ọlọrun. Ohun ti a fi dami niyẹn. Nigba gbogbo ni emi ngbagbọ ninu oore-ọfẹ. Oore-ọfẹ nimi patapata. Kii ṣe emi, nigbati mo jẹ ọmọkunrin paapaa. Emi ko le e ri ohun miran bikoṣe Oore-ọfẹ. Wọn ma a wipe, “Bi iwọ ba ranmilọwọ, emi naa yoo ran ọ lọwọ. Ọrọ ti ko dara ni. Emi ko fẹ mọ bi iwọ ranmilọwọ tabi iwọ ko ranmilọwọ, bi iwọ ba nilo iranlọwọ mi, emi yoo ṣe e lọnakọna. Ṣe o ri oore-ọfẹ. Bẹẹ ni, sa. Wo o, oore-ọfẹ nsiṣẹ nipa ifẹ. Bi iwọ ba nilo rẹ! Bi iwọ ko tilẹ ṣe ohun kan fun mi ri, ti emi ko ni nkankan ṣe pẹlu rẹ ri, bi iwọ ba nilo ohun kan, emi yoo ṣee. Oore-ọfẹ! Nitoripe iwọ nilo rẹ!

25 Mo nilo igbala. Ko si ohun kan ti o le gba mi la. Ko si ohun kan ti emi lee ṣe nipa rẹ funra mi, emi ko lee gba ara mi la. Sugbọn mo nilo igbala nitori mo gba Ọlọrun gbọ. Ọlọrun si ran Ọmọ Rẹ, ti a ṣe ni ifarahan ara ẹlẹṣẹ lati jiya ni ipo mi, a si gba mi la nipa oore-ọfẹ nikan. Ko si ohun kan ti mo lee ṣe, tabi ti iwọ lee ṣe, lati gba ara rẹ la. Awọn ti O si ti mọtẹlẹ, ṣaaju ipilẹṣẹ aye……

26 A ti bẹrẹ ẹkọ yii lati Ọjọru to kọja. A wo Ọlọrun gẹgẹ bi apele Rẹ ti El, Elah, Elohim, a si rii wipe Oun ti wa laisi Ẹniti o da A. O wa ni Oun nikanṣoṣo. Sugbọn ninu Rẹ ni agbara lati jẹ Baba, ninu Rẹ ni awọn akayẹ lati fi orisirisi nkan ti o jẹ han, gẹgẹbi Olugbala ati Oluwosan. Gbogbo nkan wọnyi wa ninu Ọlọrun, Oun si dáwà ni Oun nikan. Sugbọn niwọn ti O jẹ Olugbala, Oun ko si ni angẹli tabi ohun miran. Ko si ohun miran bikoṣe Oun nikan. O wa ni Oun nikan. Ko si si ohun miran lẹyin Rẹ.

Sugbọn nitoripe O jẹ Ọlọrun, O nilati ni ohun kan ti yoo ma a sin In, nitoripe O nifẹ isin. Akayẹ Rẹ gan ni O da awọn ti yoo maa sin In. (Bayi ẹ jẹ ki a sọ ọ lẹẹkansi, a ko ni lọ ninu rẹ patapata, sugbọn ẹ o gbọ ọ ninu fọnran naa) Sugbọn nitoripe O jẹ Ọlọrun, O da awọn angẹli, awọn angẹl si bẹrẹ si sin In. Awọn angẹli ti nduro niwaju Ọlọrun ni iyẹ apa mẹfa. Wọn fi meji bo oju wọn, wọn fi meji bo ẹsẹ wọn, wọn si nfi meji fo, ni iwaju Rẹ; wọn si nkigbe tọsan toru wipe, “Mimọ, Mimọ, Mimọ, ni Oluwa Ọlọrun Olodumare”. Ohun ti Iwe Mimọ sọ niyẹn. Wọn nsin In. O da ohun kan lati ma a sin In.

27 Ninu Rẹ, Oun ni Iwa ẹda ati ipa lati jẹ Olugbala. Bawo ni ọkan ninu awọn ẹda yẹn ṣe lee ṣubu nigbati ko si ẹṣẹ tabi ero lati dẹṣẹ? Ko le e ri bẹẹ. Nitori naa a nilati da ohun kan ti o le ṣubu sinu ẹṣẹ, ki Oun ba le jẹ Olugbala. Ninu Rẹ ni agbara lati jẹ Oluwosan. Ṣe iwọ gbagbọ pe Olugbala ni Oun iṣe? Ṣe iwọ gbagbọ wipe, Oluwosan ni? Bi o ba ṣe wipe ko si ẹnikẹni lati gbala ati lati wosan nkọ? Wo o, ohun kan ni lati wa ti o nilo iwosan tabi igbala.

Nitori naa, Oun ko da eniyan lati ṣubu, sugbọn O fi eniyan si ipo lati yan ohun ti o wu u. “Bi iwọ ba jẹ eleyi, iwọ yoo ye; Bi iwọ ba jẹ omiran, iwọ yoo ku”. Gbogbo eniyan to nwa sinu aye ni a si fun ni anfani kan naa. Ọlọrun, nipa imọtẹlẹ Rẹ mọ ẹniti yoo ṣee, ati ẹniti ki yoo ṣee.

28 Onimọ ẹkọ ẹsin kan beere lọwọ mi lana, oun si ti nwa si awọn ipade mi tabi o ti nfeti si awọn fọnran iwaasu mi. O wipe, “Mo ni ibeere kan! Ṣe Ọlọrun wa ni ibi gbogbo?”

Mo wipe, “Oun ko si nibi gbogbo gẹgẹbi afẹfẹ ṣe wa nibi gbogbo. Oun ko lee jẹ Ẹda kan ki Oun si kun gbogbo aye. Bi Oun ba kun ibi gbogbo, kilode ti iwọ yoo fi gbadura lati gba Ẹmi Mimọ. Bi Oun ba kun ibi gbogbo, a jẹ wipe, o kun gbogbo nkan, iba ṣe igi, erupẹ ilẹ, eniyan. Mo wipe, kinni idi ti O fi nwa Mose, ti O ba wa nibi gbogbo? Kin ni idi ti yoo fi maa wa Adamu ninu ọgba, ti O wipe ”Adamu, Adamu, iwọ da?“ Bi Oun ba wa nibi gbogbo?”

Oun wa nibi gbogbo nitoripe O mọ ohun gbogbo. O mo ohun gbogbo, O jẹ ailopin. Nitori ti O jẹ ailopin ni imọ ni O fi jẹ ẹniti O mọ ohun gbogbo, nitori naa ni O fi wa nibi gbogbo. O joko ni inu awọn Ọrun. O ngbe ni ibikan nitoripe Ẹnikan ni oun iṣe.

29 Nitori oun je Ailopin, nigba naa, o mọ ohun gbogbo: O mọ igbati kokoro koto-nkan yoo ṣẹju, O mọ olukuluku oyin, ati ibiti yoo lọ lati wa oyin rẹ. O mọ gbogbo ẹyẹ to duro lori igi. O mọ gbogbo ero ti o wa ni ọkan rẹ, nitori pe ailopin ni, O si mọ ohun gbogbo. Kii ṣe pe O jẹ ailopin nikan, Oun mọ ohun gbogbo. Sugbọn ẹnikan ni Oun. Ẹnikan ni Ọlọrun, lati inu Ẹniti Oun iṣe, O bẹrẹ si mu gbogbo nkan wọnyi jade.

30 Gẹgẹbi mo ti sọ lalẹ ijelo wipe, ẹṣẹ kii ṣe ẹda Ọlọrun. Ko si ohun ti Ọlọrun da ti ki i ṣe pipe. Ọlọrun da ohun gbogbo daradara. Ẹṣẹ kii ṣe ẹda ti Ọlọrun da. Ẹ ti gbọ ti awọn kan wipe, “Iṣẹda ẹṣẹ niyẹn”. Sugbọn iṣina ni iyẹn. Ẹlẹda kan ṣoṣo ni O wa, tii ṣe Ọlọrun. Ọlọrun ko le e da ẹṣẹ, nitoripe Oun jẹ Mimọ, ko si si ohun kan ninu Rẹ lati fi da ẹṣẹ. Ẹṣẹ jẹ idibajẹ kan: Kii ṣe ẹda kan. Panṣaga jẹ iṣe ododo kan ti a ti dibajẹ. Irọ jẹ otitọ ti a sọ lọna to kuna. Gbogbo ẹṣẹ ni o jẹ ododo ti a dibajẹ.

31 Nitorina, Ọlọrun duro. O si ti sọ ara Rẹ di mímọ̀ gẹgẹbi Ọlọrun. O ti fi ara Rẹ han ni Olugbala, eniyan sọnu, O si gba wọn la. O ti fi ara Rẹ han ni Oluwosan. Ko ṣe Pataki ohunkohun ti eniyan le e pe E, O jẹ Oun to jẹ, sibẹ. Oluwosan ni, Olugbala ni, Ọlọrun ni, Ainipẹkun si ni. Oun si ni afojusun kan. Afojusun Rẹ lati ipilẹ si ni wipe, ki O da awọn ẹda kan, ti yoo fẹ Ẹ, ti yoo si ma a sin In.

Oun si da awọn ẹda, awọn ẹda naa si ṣubu. Nigba naa, Ọlọrun, nipa Imọ ailopin Rẹ, bojuwo gbogbo akoko, O si ri gbogbo awọn ti a o gbala. O mọ gbogbo eniyan nipa imọtẹlẹ. Nitori naa, niwọnbi Oun, nipa imọtẹlẹ mọ gbogbo awọn ti a o gbala, ati awọn ti a ko ni gbala, Oun le e yantẹlẹ. Nitori naa, Ọrọ yii kii ṣe Ọrọ to buru pupọ, abi? Oun lee yantẹlẹ, nitoripe o mọ ẹniti yoo gba a ati awọn ti ko ni gba a. Nitori naa, ki Oun lee gba awọn ti a o gbala, O nilati ṣe etutu fun ẹṣẹ wọn. Ah, bi o ba ṣeeṣe a o debẹ laipẹ ni ẹsẹ diẹ siwaju si. O yan wa tẹlẹ si Iye ainipẹkun, nitori O mọ eniyan ti yoo pa ohun gbogbo ti si apa kan. Bi o si ti ki o ri loju awọn eniyan aye, ko ni ni itumọ kankan si wọn, nitoripe wọn jẹ ọmọ Ọlọrun.

32 O si ti pe wọn.

O si ran Jesu, ki ẹjẹ Rẹ lee ṣe ilaja, nipa etutu tabi ifọnumọ. O si jẹ ifọnumọ ti nlọ lọwọ, ki ikan ṣe iṣẹlẹ ti isọji kan, sugbọn "O wa laaye titi lati maa ṣe ilaja." Ki Kristẹni naa lee wa ni ipamọ mimọ tọsan toru. Ẹjẹ Jesu Kristi si wa niwaju Ọlọrun lati ma a fọ wa mọ nigbogbo igba, tọsan-toru kuro ninu ẹṣẹ gbogbo. A si wa ni ipamọ titi. Ipamọ ni ọna wo? Nipasẹ Ẹmi Mimọ, ninu Ara ti Jesu Oluwa. O wipe, "Ẹniti o ba gbọ Ọrọ Mi, ti o si gbagbọ ninu ẹniti O ran Mi, ni Iye ainipẹkun, oun ki yoo si wa sinu idajọ, sugbọn o ti rekọja iku bọ si Iye. Ko si idajọ fun un mọ! Kristẹni ki yoo lọ si idajọ. Kristi ti lọ si idajọ fun un. Agbẹjọro mi ti duro funmi. O ti gba ẹjọ mi ro, wipe mo jẹ alaimọkan. O sọ fun Baba wipe, emi ko yẹ, ati pe emi ko mọ nkankan. Sugbọn o fẹmi, o si gba ipo mi, o gba ẹjọ mi ro, loni, mo ti wa ni ominira! Bẹẹ ni sa. O ta ẹjẹ Rẹ silẹ, lati fi rubọ ẹṣẹ wa.

33 Ranti alẹ Ọjọru to kọja pe Kristẹni ni o ndẹṣẹ, sugbọn ẹlẹṣẹ kan ko lee dẹṣẹ. Ẹlẹṣẹ kii dẹṣẹ, nitori pe, ẹlẹṣẹ ni oun. Ẹlẹṣẹ ni oun lati ibẹrẹ, o pari. Iwọ wo ẹyin iwe yii, o dudu. Bawo ni dudu rẹ ti pọ to? Gbogbo rẹ ni o dudu. Ko si funfun kankan ninu rẹ, dudu ni. Iwọ wipe, "ipa yii ni o dudu". Rara, bẹẹ kọ, gbogbo rẹ ni o dudu. Bi ẹlẹṣẹ ṣe ri niyẹn. A ti daa lẹbi na. O dara, iwọ wipe, "Bi ẹlẹṣẹ ba ṣe pasanga nkọ? Bi oun ba ṣe obinrin kan baṣubaṣu nkọ? Bi o ba ta tẹtẹ nkọ? Bi o ba ta ibọn lu ẹnikan nkọ?" Ko si ohun to kan awa nipa iyẹn. A ni ofin orilẹ-ede lati yanju iyẹn. Awa kii ṣe alatunṣe, oniwaasu ihinrere ni awa. Awa ko da lẹbi fun ohun ti o ṣe, a ko da lẹbi nitoripe o ṣe pansaga. A da a lẹbi nitori pe o jẹ ẹlẹṣẹ. Bi o ba jẹ Kristẹni, oun ko ni ṣe e. Otitọ niyẹn. Bi a ba fi yii pada, ko ni ṣe iyẹn. Sugbọn nitoripe o jẹ ẹlẹṣẹ, ni o jẹ ki o ṣe iyẹn.

34 Ibiti otitọ ti tako awọn olofin niyẹn. Bẹẹ ni, sa. Arakunrin, mo sọ fun ọ, "Kii iṣe ofin, sugbọn nipa oore-ọfẹ ni a fi gba wa la, nipa igbagbọ." Bẹẹ ni. Bayi, emi ko da awọn arakunrin to gbe igbala lori ofin lẹbi, arakunrin mi niwọn. Wọn yoo si wa nibẹ, gẹgẹbi awọn toku yoo ṣe wa nibẹ, nitoripe Ọlọrun ti yan Ijọ Rẹ tẹlẹ lati wa nibẹ. Sugbọn nipa ohun kan yẹn, iwọ pin awọn eniyan yẹlẹyẹlẹ, wọn ko mọ ipo wọn. Wọn wipe, "Loni, o dara, boya mo wa nibẹ…" Sa jẹ ki wọn mọ wipe, niwọn igbati wọn ba ni ipongbẹ fun aye, wọn ko si nibẹ rara.

35 Emi ko fi otitọ ba iyawo mi gbe nitori ki o ma baa kọ mi silẹ. Mo gbe ni otitọ sii, nitoripe mo ni ifẹ rẹ. O jẹ ipo kan to ba ofin mu ti a ti gba, wipe a nifẹ ara wa. Ṣaaju, ki o to wa nibẹ, o nilati jẹ ifẹ. Mo nifẹ rẹ. Bi mo tilẹ gbagbọ pe, bi mo ba ṣe ohun kan ti o kuna, oun yoo dariji mi, sibẹ emi ko ni ṣe e lọnakọna. Mo nifẹ rẹ.

Bi o ti ri pẹlu Kristi niyẹn. Mo jẹ ẹni aadọta ọdun bayi. Bi mo ba si wa laaye titi di ẹni ọgọrun ọdun si, ti mo ni aadọta ọdun si lati waasu, ti emi ko si waasu kankan mọ, ti mo lọ joko si eti odo, a ti gba mi la sibẹ. Ọlọrun gba mi la nipa oore-ọfẹ Rẹ, ti emi ko si ṣe ohunkohun lati yẹ fun un. Yala ti mo ti ṣe tabi ti mo lee ṣe laye. Mo n waasu nitoripe mo nifẹ Rẹ, mo si nifẹ awọn eniyan Rẹ. Idi si niyẹn ti mo fi mọ pe, mo ti re iku kọja si iye nitori pe, mo nifẹ wọn, mo si nlepa lati mu wọn wa sile: Iru ipokipo ti o wu ki wọn wa, mo nwa wọn kiri lọnakọna. Lọ wa wọn jade lọnakọna, fa wọn jade lọnakọna. Bi awọn oniwaasu ba tako mi, ti awọn toku tako mi, ti awọn ijọ to fẹkọ-kẹkọ-rọpo Ọrọ Ọlọrun si tako mi, iyẹn ko da mi duro. Ohun kan wa! Ohun wọnyi ko da Oluwa duro! Oun wa saye laarin aigbagbọ gbogbo ko si da A duro! O tẹsiwaju lọnakọna. Ohun ti awa nṣe niyẹn, a njade lọ lati wa wọn, bi o ti wu ki o ri. Nawọ jade, gba wọn mu, di I mu sinsin pẹlu gbogbo ipa rẹ. Iwọ ko mọ ẹniti wọn jẹ. Gba wọn la. Nitori ifẹ niyẹn. Kii ṣe nitori pe mo nilati ṣe e", sugbọn nitori mo nifẹ, nitoripe iwọ nifẹ wọn.

36 O wipe "O yẹ ki emi lọ ṣe atunṣe pẹlu obinrin yẹn, sugbọn mọ sọ fun ọ pe lọwọlọwọ bayi… Mo ro pe nitori ti mo nlọ sile isin, o yẹ ki nlọ ṣe atunṣe." Rara, iwọ ni o nilati kọkọ mu ara rẹ tọ na. Bi iwọ ko ba ni ifẹ Ọlọrun ni ọkan rẹ, ko wulo. Ohun kan nilati fi ye ọ pe, o kuna, nigba naa, lọ ṣe atunṣe pẹlu Ọlọrun, lẹyin naa, iwọ lee ṣe atunṣe pẹlu aladugbo rẹ.

Jesu kọ́ ohun yii. O wipe, "Bi iwọ ba wa sibi pẹpẹ, ti iwọ si ranti pe o ni ohun kan lodi si aladugbo tabi arakunrin rẹ, lọ ṣe atunṣe pẹlu rẹ ṣaaju na".

37 Bayi ninu awọn iran ti nbọ wa. A ti kọ́ ni ọjọru ti o kọja nipa awọn ifarahan-fayẹri. A o tun ṣe lowurọ yii, nipa ifarahan-fayeri ti awọn ọmọ Ọlọrun, nibiti Ọlọrun ti n duro. Ni opin akoko, nigbati gbogbo wa yoo duro niwaju Rẹ. Awọn angẹli ko sọ nu. Wọn ko lee mọ lati jẹ igbadun Ibukun naa bi awa yoo ti ṣe, wọn ko fi igba kankan sọ nu ri. Sugbọn emi mọ ibiti mo ti wa. Mo mọ apata ti a ti wu mi jade, ẹlẹṣẹ ni. Iwọ mọ ibiti a ti mu ọ jade. Nigbati a ti gba wa la, nigba naa, a lee duro niwaju Ọlọrun. Ah, ọjọ nla ni yoo jẹ!

38 Nigba naa, isọdọmọ, ifini-sipo. Bayi, Ọlọrun nṣe iṣẹ yii. Bi mo ba si lee fi eyi yee yin, nitori naa, a o bẹrẹ bayi ni ẹsẹ karun. Mo fẹ ka a:

Ẹniti o ti yan wa tẹlẹ si isọdọmọ nipa Jesu Kristi fun ara Rẹ, gẹgẹ bi idunnu ifẹ Rẹ.

O jẹ inu didun Ọlọrun lati ṣe ifẹ Rẹ - isọdọmọ, ifini-sipo. Kin ni O nṣe bayi? O n fi Ijọ Rẹ sipo. Ṣaaju, O pe ijọ Rẹ - lati Methodisti, Presibiteria, Lutheria, Baptisti - O pe wọn. Lẹyin naa kin ni O ṣe? O ran Ẹmi Mimọ, O fun wọn ni ibaptisimu Ẹmi Mimọ.

39 Mo fẹ ki ẹyin Pẹntikọsita mu eleyi kuro ni ọkan yin. Pẹntikọsti kii ṣe ẹgbẹ ẹsin kan, Pẹntikọsti jẹ iriri kan. Ẹmi Mimọ ni. Kii ṣe ẹgbẹ ẹlẹsin-to-feniyan-sadari-rọpo-Ẹmi Mimọ, Iwọ ko lee fi Ẹmi Mimọ sabẹ isakoso eniyan. Ko ni gba fun ọ. Ẹyin ti ni ẹgbẹ kan, ijọ ẹgbẹ ẹlẹsin kan ti ẹ npe ni Pẹntikọsita, sugbọn Ẹmi Mimọ jade lọ kuro, o si fi yin silẹ sibi ti ẹ joko si, Oun si tẹsiwaju. Pẹntikọsti kii ṣe ẹgbẹ ijọ ẹlẹsin kan. Pẹntikọsti jẹ iriri ti Ẹmi Mimọ.

40 Nigba naa, Ọlọrun fun awọn Tirẹ ni ibi titun nipa ibaptisimu Ẹmi Mimọ. Wọn wa si tosi rẹ nigbati wọn fọ ara wọn mọ, gẹgẹbi Ijọ Nasarẹni, Ijọ Atipo Iwa Mimọ (Pilgrim Holiness), lẹyin naa wọn wa sinu iriri ti Pẹntikosti, tabi ibaptisimi Ẹmi Mimọ, ti wọn gba imupada wa ti awọn ẹbun. Wọn jade lọ, wọn si n fede sọrọ, wọn ntumọ ede titun, a si fun wọn ni awọn ẹbun ti iwosan ati isẹ ami ati ara si bẹrẹ si tẹlẹ wọn. Bayi, ọmọ niwọn. Ọmọ Ọlọrun ni wọn. Wọn wa ninu Kristi. Wọn ti di ọmọ nipasẹ atunbi. Ibi titun ati iyipada naa si ni Ẹmi Mimọ.

A ko tilẹ tii yi ọ lọkan pada titi ti iwọ ba gba Ẹmi Mimọ. Ohun ti Iwe Mimọ sọ niyẹn. Jesu sọ fun Peteru, iwọ beere lọwọ ẹnikẹni, ka iwe Mimọ rẹ. A da a lare nipa igbagbọ ninu Jesu Oluwa. O si di ọmọ ẹyin, o di aposteli kan. Jesu fun un ni awọn kọkọrọ Ijọba naa. Ni Johanu 17: 17, O sọ wọn di mimọ, O fun wọn ni agbara, O si ran wọn jade lati le awọn ẹmi eṣu jade ati bẹẹ bẹẹ lọ, O sọ wọn di mimọ, “Sọ wọn di mimọ Baba, nipasẹ otitọ Rẹ, Ọrọ Rẹ ni otitọ. Emi yara mi si mimọ nitori wọn”.

41 Iyẹn jẹ ọkan ninu awọn ọrọ to dun julọ ti mo tii gbọ ri. “Baba, mo ya ara mi si mimọ nitori tiwọn” Njẹ o mọ wipe, Jesu ni ẹtọ lati ni ẹbi kan? Ẹniyan ni Oun: Njẹ o mọ pe o ni ẹtọ lati fẹ iyawo? Ọkunrin ni oun. O ni ẹtọ si gbogbo nkan wọnyi, sugbọn o wipe, “Baba. Mo ya ara Mi si mimọ nitori tiwọn. Mo yara mi si mimọ”.

42 Mo ba oniwaasu kekere kan sọrọ ni ana. Emi yoo waasu fun un ni ile isin rẹ lẹyin ọjọ diẹ si bayi, ni opopo masọsẹ. Mo si beere oun kan lọwọ rẹ. O wipe, “Bẹẹni, Arakunrin Branham, sugbọn awọn to pọ julọ ninu awọn eniyan mi ko gba iyẹn gbọ”

Mo wipe, “Olofin lo pọ ju ninu wọn?”

O wipe, “Bẹẹ ni.” Arakunrin naa ko gba iyẹn gbọ. “Sugbọn nitori tiwọn, mo ya ara mi si mimọ.” Mo fẹ wà á mọ́ra nitori ohun ti o sọ yẹn.

43 Ah Jesu nkọ awọn ọkunrin mejila, ati nipa awọn mejila naa, ni a o fi mu ihinrere lọ si gbogbo aye. O si wipe, Nitori tiwọn, Mo ya ara Mi si Mimọ“. Iwọ ṣe ara rẹ fun anfani aladugbo rẹ, fun anfani ẹlomiran. ”Ma ṣe lo ominira rẹ fun bibo ohun ti ko dara mọlẹ,“ gẹgẹbi Paulu ti wi. Sugbọn ya ara rẹ si mimọ.” Huwa si aladugbo rẹ gẹgẹbi Kristẹni. Jẹ ki isọrọ rẹ ki o jẹ eyi ti a fi iyọ dun. Bi iwọ ba ri ọta rẹ, ya ara rẹ si mimọ nitori rẹ.

44 Fifi ọmọ sipo. Ohun kin-ni, ni wipe, a bi ọmọkunrin kan sinu ẹbi kan, sugbọn a rii wipe, iwa rẹ ni o mu ki o yẹ fun isọdọmọ - yala o huwa to tọ tabi ko ṣe bẹ ẹ.

O si jẹ awọn Pẹntikọsita…. Sa jẹ ki nfihan ọ pe, Pẹntikosti kii ṣe ẹgbẹ-ijọ-ẹlẹsin kan. Baptisti melo lo wa nibi ti o ti gba Ẹmi Mimọ? Ẹ na ọwọ soke? Mẹtọdisti melo lo wa nibi ti o ti gba Ẹmi Mimọ? Ẹ na ọwọ soke. Awọn ọmọ Ijọ Nasarinni melo lo wa nibi ti o si ti gba Ẹmi Mimọ? Na ọwọ rẹ soke. Pirẹsibiteria, to ti gba Ẹmi Mimọ? Lutheria, awọn ijọ miran ti kii ṣe Pẹntikosita rara, ti wọn si ti gba Ẹmi Mimọ? Ẹ nawọ yin. Ṣe o rii. Nitori naa, Pẹntikọsti kii ṣe ijọ-ẹlẹkọ-adamọ kan, iriri kan ni.

45 Bayi, Ọlọrun mu ọ wa sinu ara Kristi. Kin ni oun si ṣe? Lẹyin igbati iwọ ti mu ara rẹ yanju ti o yara rẹ si mimọ pẹlu iwa rere ni igbọran si Ẹmi Mimọ, lai bikita fun ohun ti aye sọ.

46 Emi fẹ tẹnumọ eleyi gidi, emi ko si fẹ fi ṣe ọyaju. Jọwọ maṣe ro wipe mo buru. Emi ko fẹ ṣe bẹẹ. Ohun to nṣe mi ni kayefi ni wipe, Lẹyin ti mo ba waasu otitọ ti Ọlọrun fi ran mi yii, awọn eniyan yoo si yiju pada, lati maa ṣe ohun ti wọn nṣe tẹlẹ, wọn si njẹwọ pe awọn ni Ẹmi Mimọ. Iyẹn tilẹ fẹrẹ ẹ pa mi. Kin ni o nṣẹlẹ? Wọn pada si oju kan naa gẹgẹbi awọn ọmọ Israeli. Wọn fẹ jẹ ọba kan, ki ọba naa le maa sakoso le wọn lori, ki wọn si ṣe gẹgẹbi awọn ara Amori ti n ṣe, ati awọn Amaleki ati awọn Filistini.

47 Ṣe iwọ mọ, iwọ obinrin pe o kuna fun ọ lati wọ ṣokoto ọkunrin? Ṣe iwọ mọ iyẹn? Ṣe iwọ mọ wipe o kuna fun ọ lati ge irun ori rẹ? Ṣe iwọ mọ iwọ ọkunrin pe o kuna fun ọ lati mu siga ati awọn ohun ti o nṣe? Ṣe o mọ wipe o kuna ki iwọ ma jẹ ọkọ lori ile rẹ? Iyawo rẹ yoo binu, yoo si le ọ kuro ni ile, iwọ yoo si wipe, “Bẹ ẹ ni, ki a bukun ọkan rẹ, olufẹ mi, emi yoo tun pada wa?” Bawo ni iwọ ṣe lee ṣe akoso ile Ọlọrun nigbati iwọ ko tilẹ lee ṣe akoso ile rẹ? Otitọ gẹlẹ niyẹn. Njẹ iwọ mọ arabinrin wipe, ọkọ rẹ kii ṣe ọkọ rẹ nikan, sugbọn oun ni alakoso lori rẹ? Ọlọrun sọ bẹ ẹ, nitoripe, a ko tan ọkọ naa jẹ. A tan obinrin naa jẹ. Ẹyin oniwaasu si tẹsiwaju lati maa fi obinrin se olusọ-aguntan ati oniwaasu ninu ijọ yin, ti ẹ si mọ wipe Ọrọ Ọlọrun da iyẹn lẹbi.

48 Ẹ si nfi apele Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ ṣe itẹbọmi nigbati ko si Iwe mimọ kankan fun un ninu Bibeli. Mo fẹ ki olori awọn bisọbu tabi ẹlomiran wa fihan mi ninu Bibeli bi o ba ri ibiti a ti ṣe itẹbọmi ni orukọ Baba, Ọmọ,

ati Ẹmi Mimọ. Mo fẹ ki ẹnikan wa fihan mi bi a ba ri ẹnikẹni ti a ṣe itẹbọmi fun yatọ si orukọ Jesu. Awọn ti Johanu ti ṣe itẹbọmi fun, se ijẹwọ igbagbọ wipe Olugbala nbọ, sugbọn wọn ko mọ Ẹniti o jẹ. Sugbọn lọgan ti wọn mọ iyẹn, wọn nilati ṣe itẹbọmi miran fun wọn ni orukọ Jesu Kristi. Mo fẹ ki ẹnikan wa fihan mi. Mo ti beere lọwọ Ijọ Akọjọpọ ti Ọlọrun (Assemblies of God) Mo ti beere lọwọ awọn oniwaasu miran, awọn Baptisti, Presibiteria, ati gbogbo wọn. Ah, wọn ko ni sọrọ nipa rẹ. Mo fẹ ri Iwe Mimọ naa.

Mo si ti di agba-were-mẹsin, abi? Nigba naa, o ro wipe mo siwin, ori mi daru, mo ya were, nitori pe mo ngbiyanju lati sọ otitọ fun yin. Otitọ niyẹn, ẹyin ara. Bi eniyan ba fi ara rẹ fun Ọlọrun, O fi ara rẹ fun Un patapata. A ti ya ọ sọtọ. Ẹda ọtọ ni ọ.

49 Ọpọ ni a pe, diẹ ni a yan. Ọpọ eniyan ni a pe. Bi iwọ ba ni ipe kan ni ọkan rẹ, Iwọ wipe, "Bẹẹni, mo gba pe Ọlọrun fẹran mi." Mo gba bẹẹ.

Sugbọn, arakunrin, iwọ yoo ṣegbe gẹgẹbi awọn ti o ku, nitori wọn yoo wa lọjọ naa, ti wọn yoo wipe, Oluwa, emi ti le ẹmi eṣu jade ni orukọ rẹ. Mo ti ṣe ohun pupọ ni orukọ Rẹ. Mo ti ṣe isin iwosan. Mo ti waasu ihinrere. Mo ti le ẹmi eṣu jade".

Jesu yoo wipe, "Kuro lọdọ mi. Emi ko tilẹ mọ ọ ri, iwọ agabagebe. Ẹniti o ba ṣe ifẹ Baba Mi nikan ni". Kin ni idi ti awọn eniyan ko fi ri otitọ wọnyi? Mo mọ pe, iyẹn jẹ inira. Emi ko ni in lọkan lati sẹ yin. Emi ko fẹ ki o jọ bẹẹ, sugbọn arakunrin wo o.

50 O jọ loju mi wipe, a ti wa ni opin ọjọ, Ọlọrun si nsọ awọn eniyan di ọmọ. O nfi Ijọ Rẹ si ipo wọn, ninu ara Kristi. Awọn ti Oun yoo fi sibẹ ko ni pọ rara. Mo kọkọ sọ iyẹn fun ọ ni ibẹrẹ. Iwọ lee sọ wipe, awọn to pọ niye ni yoo wa nibẹ". Sugbọn Oun ti ni ẹgbẹrun ọdun mẹfa lati sa wọn jade pẹlu. Ranti pe, ajinde yoo de, a o si gba wa soke pẹlu wọn. Awọn perete ni. Iwọ tete wadi igbala rẹ yanju. Iwọ funra rẹ wo yika, ki o si wadi ohun ti o kuna. Wadi ohun to ṣẹlẹ. Mo mọ pe iyẹn le, arakunrin, sugbọn otitọ ni. Otitọ Ọlọrun ni.

Isọdọmọ!

51 A gbọdọ gbina fun Ọlọrun, a nilati ma a tẹsiwaju tọsan toru. Ko si ohun to yẹ ko dawa lẹkun. O si yẹ ki a kun fun adun ati ifẹ, ki a ni aanu ati iwa rere gẹgẹ bi i ti Kristi laye wa. O ngba igbe aye ojoojumọ. Jesu wipe, kiyesi ododo lili ninu igbo, bi o ṣe ndagba (to nṣe laalaa): sibẹ, mo sọ fun yin pe, a ko ṣe Solomon logo, pẹlu gbogbo ogo rẹ to ọkan lara wọn." Solomoni ni awọn aṣọ igunwa ati aṣọ ti a fi ikosẹ ṣe ọna si, sugbọn kii ṣe ohun ti a nsọrọ nipa rẹ niyẹn. Ki lili to le dagba, o nilati maa sa ipa lọsan ati loru. Kin ni iwọ fẹ pada sẹyin fun? Bi o ba ṣe wipe, agbara kaka ni a o fi gba eniyan olododo la, nibo ni ẹlẹṣẹ (iyẹn ni alaigbagbọ) ati alaiwabi-Ọlọrun (ẹnikan to gbọ Ọrọ Ọlọrun, ti o si kọ lati rin ninu rẹ) yoo ṣe? Kin ni a o ṣe bayi?

52 Ijọ tiwa niyi. A ni awọn alejo mẹrin tabi marun laarin wa. Sugbọn Ijọ wa niyi. Mo nkọ yin. A gba iwaasu yii silẹ sori fọnran kan. Mo fẹ ki awọn to nfetisi fọnran iwaasu mọ wipe, eyi wa fun ijọ mi. Laarin awọn eniyan ni ibomiran, mo maa n gbiyanju lati jẹ ọmọluwabi ni biba wọn sọrọ, mo maa nṣe wọn bi ọmọ ọwọ ti a nilati fun ni wara jẹ. Sugbọn bi a ba fẹ sọ otitọ gan, ẹ jẹ ki a sọ ọ.

53 Isọdọmọ, fifi si ipo ti o yẹ! Awọn da? Fi ibiti wọn wa han mi? Ọlọrun npe ijọ Rẹ sọtọ nipa ifihan-fayeri. Wọn ko nilati sọ ohun kan nipa rẹ, ẹ o ri ohun to nṣẹlẹ. Fifi ọmọ Rẹ si ipo to tọ, mimu ọmọ Rẹ wa ni ilana pẹlu ohun kan naa ti Oun jẹ. Ọmọ naa ni aṣẹ kan naa, ọrọ rẹ ni ipa kan naa pẹlu olori angẹli tabi jubẹẹ lọ pẹlu. A ti fi ọmọkunrin yii si ipo, a gbe e ga si ibi kan, a paarọ aṣọ rẹ ati awọ rẹ. Baba rẹ si ṣe aṣeyẹ kan, o wipe, "Eyi ni ayanfẹ ọmọ mi. Lati oni lọ oun ni alakoso. O ti di alasẹ. Oun ni o wa nipo akoso lori gbogbo ogún Mi. Ohun gbogbo ti mo ni, di tirẹ". Otitọ niyẹn.

54 Nigba naa, a lee pada wa si ero ti El, Elah, Elohim kan naa, nibiti Ọlọrun ti jẹ Ẹnikan to da wa loun nikan. Lẹyin naa, o wa gẹgẹbi Jehofa, Ẹniti O ti da ohun kan. O si fi eniyan jẹ alokoso lori aye. Kin ni a n duro de? Ifarahan-fayeri naa. Aye nkerora. Jẹ ki a kaa. O dara.

Ẹniti o ti yan wa tẹlẹ si isọdọmọ nipa Jesu Kristi fun ara Rẹ, gẹgẹ bi idunnun ifẹ rẹ.

Fun iyin ogo oore-ọfẹ Rẹ eyiti o dalu wa ninu Ayanfẹ ni.

Kin ni oore-ọfẹ? Ṣaaju ipilẹsẹ, nigbati Oun ko ti di Baba, ifẹ Rẹ, Oore-ọfẹ Rẹ, pese ọmọ kan fun Un, ki a le yan wa tẹlẹ si isọdọmọ awọn ọmọ Rẹ, fun iyin oore-ọfẹ rẹ.

……Ninu ẹyiti O ti sọ wa di itẹwọgba nipasẹ Ẹni Ayanfẹ naa tii ṣe Kristi.

O sọ wa di ẹni itẹwọgba bawo? Nipasẹ Rẹ. Bawo ni a ṣe nde inu Rẹ? Nipa Ẹmi kan, ni a baptisti gbogbo wa sinu Rẹ.

Ninu Ẹniti awa ni irapada nipasẹ ẹjẹ Rẹ, a ni idariji Ẹsẹ.

55 Bawo ni a ṣe lee waasu iyantẹlẹ Ọlọrun bi ko ba si etutu fun ẹṣẹ nibikan? Tori kinni? Loojumọ ni iwọ nṣe asiṣe, lojoojumọ ni iwọ nṣe ohun to kuna. Sugbọn bi a ba ti tun ọ bi, ọkunrin tabi obinrin ni kete ti o ba ṣe asiṣe naa, Ọlọrun mọ wipe, iwọ ni ibanujẹ fun un. Iwọ le duro niwaju aarẹ orilẹ ede tabi ẹnikẹni ki iwọ jẹwọ pe, "Mo kuna. Ọlọrun dariji mi fun ohun yii." Tori kin ni? Etutu nipa ẹjẹ kan wa.

Iwọ kiyesi pe, o sọ nipa idariji awọn ẹsẹ. Ẹlẹṣẹ je ẹlẹṣẹ, oun kii dẹṣẹ. Sugbọn ijọ lo ndẹṣẹ - o nṣe ohun ti ko tọ, o nni ero to kuna, o ni igbimọ ọkan to kuna, o n nni aigbọra-ẹni ye, o nwọ nilẹ bi ọmọde to ngbiyanju lati rin. Oun ko ti mọ bi a tii nrin daradara nitoripe, ọmọkunrin kekere ni. Sugbọn a ni ọwọ kan, to ndi wa mu, to ntọ wa, to nsọ wipe "Gbe isisẹ yii bayi ọmọ mi" Oun kii mu wa, ko na wa, nitoripe a ṣe asiṣe. Oun ki i luwa pa nitoripe a ngbiyanju lati rin. O nifẹ wa gẹgẹbi a ti nfẹ awọn ọmọ wa.

56 Baba to dara ko ni na ọmọ rẹ nigbati o ba ngbiyanju lati rin, ti o si ṣubu silẹ. Oun yoo gbe e dide pẹlu ọwọ to lagbara, yoo wipe, "Bayi ni ki iwọ ṣe ṣe ọmọ mi. Rin ni ọna yii".

Bi Ọlọrun ti n ṣe si Ijọ Rẹ niyẹn. Oun yoo bẹrẹ mọlẹ, yoo si gbe e si apa Rẹ, yoo si wipe, "Rin ni ọna bayi ọmọ Mi. Wo maṣe sọrọ ni ọna yẹn. Sọ ọ ni ọna yii. Emi ko si bikita ohun ti ijọ tabi ẹnikẹni sọ, iwọ sọ ọ bayi. Bi eleyi - ohun niyi. Bi Ọrọ Mi ba ti waasu rẹ, iwọ duro ti I, ki o rin bẹẹ gẹgẹ! Duro ti i. Maṣe wo ohun ti ẹnikẹni le e sọ, duro ti Ọrọ naa. Rin ni ọna yii. Bi a ti n ṣe e niyi".

57 O ti ṣe etutu fun ẹṣẹ wa nipa ifẹ Rẹ, bikoṣe bẹẹ, a ko lee ni anfani kankan. A lee di awọn Ọrọ naa mu.

……..Ni ibamu pẹlu Ọrọ oore-ọfẹ Rẹ

Nipa eyiti o ti sọ di pupọ fun wa

Kin ni pupọ jẹ? O ti sọ pupọ - ọpọlọpọ rẹ.

Eyiti o sọ di pupọ fun wa ninu gbogbo ọgbọn ati oye.

Oye - gbogbo ọgbọn ni o ti sọ di pupọ fun wa. Pẹlu gbogbo ọgbọn. Kii ṣe ọgbọn ti aye. Ọgbọn ti aye jẹ omugọ si Ọlọrun, ọgbọn Ọlọrun si jẹ omugọ si aye. Gẹgẹbi ọsan ati oru, wọn ko lee gba fun ara wọn. Sugbọn nigbati oorun ba yọ, ti imọlẹ owurọ si de, okunkun yoo fo lọ lati ibikan si ibomiran. Nigbati imọlẹ ihinrere ba si bẹrẹ si wọle, gbogbo ohun ti aye yoo bẹrẹ si poora. Kin ni o si nṣe? O mu ki imọlẹ naa pọ si fun awọn ọmọ Rẹ, ti wọn nrin ninu imọlẹ, ti a nfi Ẹmi Mimọ dari wọn, ti wọn nduro nipa oore-ọfẹ, pẹlu gbogbo ọgbọn ati oye, lati mọ bi a ti nrin. Bi o ba ri pe ohun kan kuna, ṣọra nipa rẹ. Oye - ti o ṣọra lati ni idaniloju ki o to ṣe e, ki o mọ bi o ṣe nilati ṣee. "Ki o gbọn bi ejo, ki o si jẹ oniwa tutu bi adaba". Ohun ti Jesu sọ niyẹn.

58 Ah, awọn ẹsẹ wura niwọnyi, ẹyin ọrẹ! A tilẹ le e duro lori wọn fun ọpọlọpọ ọjọ. Sẹ wọn ko dara pupọ bi? Oye ati ọgbọn ni o ti sọ di pupọ fun wa, o da a le wa lori. Ko fun wa ni iwọn kekere, sugbọn O n bu wọn fun wa lọpọlọpọ bẹẹ. O ti bukun wa pẹlu ọgbọn ati oye lọpọlọpọ nipa oore-ọfẹ Rẹ! Ah, oore-ọfẹ iyanu, bawo lo ṣe dun to! Bayi:

Eyiti o sọ di pupọ fun wa ninu ọgbọn ati oye,

Ẹniti o ti sọ ohun ijinlẹ ifẹ Rẹ di mímọ̀ fun wa gẹgẹ bi idunnu Rẹ, eyiti O ti pinnu ninu Rẹ.

Tani o nba sọrọ? Ṣe awọn ijọ-ẹlẹkọ-adamọ ni? Jọwọ ẹyin ara mi, ẹ maṣe ro wipe emi nba ijọ yin jẹ. Rara. Mo ngbiyanju lati sọ fun yin pe, o kuna lati ibẹrẹ. Jesu wipe, "Lọ waasu ihinrere", a si lọ kọ awọn ijọ-to-fẹkọ-adamọ-rọpo-ọrọ-Ọlọrun. Idi niyẹn ti a ko fi ni otitọ. A nrin nipa ọgbọn eniyan.

Bi Calvin ba le ji dide ni.

59 Kinla, Mo duro laipẹ yii nibi iboji eniyan nla kan, tii ṣe alatunṣe-ijọ kan. Mo si roo wipe, ẹni nla kan ni o jẹ. Bẹẹni. John Wesley ni. Mo si roo wipe, bi John Wesley ba lee ji dide lati iboji rẹ yii loni, ki o si ri ipo ti ijọ rẹ wa, oju orukọ rẹ yoo tii. John Wesley jẹ ọkunrin ẹni iwa-bi-Ọlọrun kan, ẹnikan to gbina fun Ọlọrun. John Wesley jẹ ẹni Mimọ kan to gba Ọlọrun gbọ, to si rin ni sisẹ-ntẹ-le pẹlu Ọlọrun. Sugbọn lẹyin ti o ku, wọn wipe," Awa yoo da Ijọ kan silẹ fun orukọ rẹ, a o si pe e ni Ijọ Methọdisti nitori ilana isọdi mimọ rẹ̀, ti o jẹ iṣẹ keji ti oore-ọfẹ"

Nigba naa, wọn da ijọ kan silẹ, loni awọn eniyan ijọ naa ṣẹ́ gbogbo nkan ti John Wesley waasu. John Wesley waasu iwosan nipa agbara Ọlọrun. John Wesley gbagbọ ninu ibaptisimu ti Ẹmi Mimọ. John Wesley gbagbọ ninu imupada bọwa awọn ẹbun Ẹmi Mimọ. John Wesley, Martin Luther ati ọpọ awọn eniyan nla yẹn ni o fi ede titun sọrọ, ti wọn si tumọ ede. Sugbọn loni, bi ẹnikan ba sọrọ pẹlu ede titun ninu Ijọ Methọdisti, tabi ijọ Luther, wọn yoo lee jade kia. Kin ni o ṣẹlẹ? Ni akoko ti o yẹ ki a fi wa sipo gẹgẹbi ọmọ Ọlọrun, kin ni o ṣe wa? Wọn ti gba ohun miran, nitori pe wọn ko mọ ijinlẹ Ọlọrun. Wọn ko si lee mọ ọn laelae nipa ile ẹkọ ẹsin.

60 Jẹ ki n ka ohun kan fun ọ. Ṣe o dara? O dara. Mo kọ ohun kan silẹ nibi yii. Jẹ ki a wo ohun ti Paulu sọ. Eyi ni Olukọni otitọ naa. Jẹ ki a ṣi iṣe Ẹmi Mimọ ninu awọn Aposteli 9:5. Jẹ ki n mọ igbati akoko mi ba to. (Lati ẹsẹ kinni. Iṣe Awọn Aposteli 9:1):

Sugbọn Saulu, o nmi ẹmi ikilọ ati pipa sibẹ si awọn ọmọ ẹyin Oluwa, O tọ olori alufa lọ.

O beere iwe lọwọ rẹ si Damasku si awọn Sinagọgu pe, bi oun ba ri ẹnikẹni nibẹ ni Ọna yii, iba ṣe ọkunrin, iba ṣe obinrin, ki oun le mu wọn ni dide wa si Jerusalẹmu.

O wipe, "Emi yoo lọ tiwọn mọlẹ. Bi mo ba sa ri eyikeyi wọn, ohun ti n o ṣe fun wọn, sa jẹ ki nri wọn! Sugbọn ẹniti a ti yanfẹ ni.

61 Bawo ni o ṣe mọ pe ọkunrin ọmuti yẹn kii ṣe ẹniti a yantẹlẹ si Iye? Bawo ni o ṣe mọ boya obinrin alarinkiri, aṣẹwo-oju-popo yẹn ti iwọ ko tilẹ ni sọrọ si yẹn kii ṣe ẹniti a ti yantẹlẹ? Bawo ni o ṣe mọ wipe, bi iwọ ba bọ ọ lọwọ, ti o si pe e wa si isin, ki yoo sọ ọ di eniyan mimọ ninu ogo? Bawo lo ṣe mọ wipe a ko yan an tẹlẹ? Ohun ti a ko mọ niyẹn. Sugbọn ojuṣe wa ni. Gẹgẹbi apẹja kan ti o sọ awọn sinu okun, ti o si fa a jade, o mu akere, ẹja, alangba, alantakun odo, ati orisirisi nkan miran. Sugbọn diẹ ninu wọn jẹ ẹja. Oun ko mọ, o sa ju awọn rẹ ni. Ohun ti awa nṣe niyẹn. Kiyesi Paulu:

O beere iwe lọwọ rẹ lọ si Damasku, si awọn Sinagọgu. Pe bi oun ba ri ẹnikẹni ni ọna yii, yala o jẹ ọkunrin tabi obinrin, ki oun le mu wọn ni dide wa si Jerusalemu. (Arakunrin, o jẹ alagidi!)

O si ṣe, bi o ti nlọ, o si sunmọ Damasku; lojiji, lati ọrun wa, imọlẹ si mọlẹ yii ka:

Ṣe o ka wipe, "Alufaa kan si wa loju popo naa, tii ṣe ọmọwe F.F. Jones, o si sọ fun un pe, "Iwọ nilo iriri ile-ẹkọ ẹsin kan, ọmọkunrin, mo si gbagbọ pe Ọlọrun lee lo ọ". Njẹ iyẹn ko ni jẹ akọsilẹ buburu ninu Iwe Mimọ? Emi ko fi iyẹn ṣe awada. Gẹgẹ bẹẹ ni koṣe mọgbọn wa loni, nigbati a ba wipe, "Ṣe o mọ, iya rẹ jẹ ẹni rere, mo si gbagbọ wipe iwọ yoo jẹ oniwaasu to dara".

62 Kiyesi ohun to ṣẹlẹ:

Bi oun si ti nlọ, o sunmọ Damasku: lojiji imọlẹ kan tan yii ka (Ah, ohun to ju ẹda lọ kan lo ṣẹlẹ) imọlẹ kan lati ọrun:

O si ṣubu lulẹ, o gbọ ohun ti o nfọ si I pe, "Saulu, Saulu, e e ṣe ti iwọ fi nṣe inunibini si Mi?

O si wipe, iwọ tani Oluwa? Oluwa si wipe, "Emi Jesu ni, ẹniti iwọ nṣe inunibini si I ohun irora ni fun ọ lati tapa si ẹgun.

O si wariri, ẹnu si ya a, o wipe, Oluwa kin ni iwọ fẹ ki emi ki o ṣe? Oluwa si wi fun un pe. Dide, ki o si lọ si ilu naa, a o sọ fun ọ, ohun ti iwọ yoo ṣe.

63 Oun pẹlu awọn ti o ba a rin irin-ajo si tẹsiwaju, wọn si ni ọkunrin kan nibẹ ti njẹ Anania. Anania si ri iran kan - nipa agbara Ọlọrun nibiti o ti ngbadura ni ile rẹ (wolii ni oun iṣe) Oluwa si wi fun un pe, "Ọkunrin kan nbọ wa loju popo, Oun si ti fọju, orukọ rẹ ni Saulu. Oun ni Saulu ti Tarsu."

Anania wipe, "Oluwa, mo ti gbọ iroyin ọkunrin yii. Ma ran mi, ẹni kekekere ni emi. Ma ran mi lọ ba a." Oluwa wipe, "Sugbọn kiyesi, Emi ti fi iran kan han fun un ni oju ọna rẹ wa sibi yii. Mo fara han fun un gẹgẹbi ọwọn ina. Mo ti kọlu u o si ti fọju. Mo si nilati mu ki o fọju, ki n si fa a ya, ki n to lee mu ohun to dara jade ninu rẹ. Ṣe o rii, mo nilati fa gbogbo ẹkọ ẹsin rẹ ya. Ṣe o mọ wipe, ọkan ninu awọn omọwe eniyan giga kan ni ninu ijọ nla yẹn. O ti gba ọpọlọpọ oye ti imọ ẹkọ Bibẹli. Ko nilo ki o kọ ohunkohun. Ohun ti mo nilati ṣe ni ki n gba gbogbo ẹkọ ẹsin inu rẹ danu"

64 Ohun ti o jẹ niyẹn. Kii ṣe ki a ko ẹkọ pupọ sinu rẹ si i, sugbọn ki a mu wọn kuro ninu rẹ. Mo ro wipe ohun ti o ṣẹlẹ si ọpọ awọn oniwaasu wa loni niyẹn - a nilati mu kuro ninu wọn, ki Ọlọrun le e fi Ẹmi Mimọ sinu wọn. Mu un kuro.

Anania wipe, "Oluwa sugbọn onroro ni ọkunrin yii."

Oluwa wipe, "Sugbọn wo o, o ngbadura. Bayi, iwọ lọ si adugbo naa, iwọ yoo ri orisun kan. Iwo yoo kọja orisun yẹn ni ọwọ osi, ki o si lọ siwaju. Ile funfun kan wa nibẹ. Lọ kan ilẹkun ile naa. Sa wọ inu gbọngan ile naa, iwọ yoo ri I ti o dubulẹ. Gbe ọwọ rẹ le e ki o si mu un lọ si odo Damasku, ki o ṣe itẹbọmi fun un ni orukọ Jesu, nitori mo sọ fun un, ohun ti Emi yoo ṣe. Oun yoo jiya pupọ fun Mi, nitori ojisẹ Mi ni si awọn keferi". Amin.

65 "Duro na Oluwa! Ile iwe wo ni ki n gba a nimọran?" Emi yoo sọ fun ọ ohun ti a o ṣe, jẹ ki a ka Galatia lati

rii. Jẹ ki a ka Galatia ori kinni, ki a bẹrẹ ni ẹsẹ kẹwa ki a lee ri ile-iwe ti Paulu lọ si, ati ọwọ ti a gbe le e, ati ohun ti o se. Jẹ ki a ka lati igbala Paulu, ẹsẹ kẹwa.

Njẹ nisisiyi, eniyan ni emi nyi lọkan pada tabi Ọlọrun? Tabi eniyan ni emi nfẹ lati wu? Nitoripe, bi emi ka si nwu eniyan, emi ki yoo le ṣe iransẹ Kristi.

Ah ah, ah! Jẹ ki nsọ ohun kekere kan ṣaaju eleyi. Galatia 1:8. Ẹyin melo ni ẹ mọ wipe Paulu lo mu ki awọn eniyan ṣe itẹbọmi nigba keji lorukọ Jesu ni iṣe Aposteli 19? Dajudaju, o ṣe bẹẹ. Jẹ ki a bẹrẹ si ka lati ẹsẹ kẹjọ bayi.

Sugbọn bi o ṣe awa ni, tabi angẹli kan lati ọrun wa, ni o ba waasu ihinrere miran fun yin ju eyiti a ti waasu fun yin lọ, jẹ ki o di ẹni ifibu.

“Nibo ni iwọ ti gba ihinrere yii, Paulu? Ẹsẹ ikẹsan:

Bi awa tiwi ṣaaju, bẹẹ ni mo si tun wi nisisiyi pe, Bi ẹnikan ba waasu ihinrere miran fun yin ju ẹyiti ẹyin ti gba lọ, jẹ ki o di ẹni ifibu.

Bi o ba jẹ olori angẹli, bi o ṣe bisọbu, bi o jẹ alakoso agba, bi o ṣe ọmọwe kan, ẹnikẹni ti o lee jẹ, bi oun ko ba waasu itẹbọmi lorukọ Jesu Kristi, ibaptisimu Ẹmi Mimọ, ti ko waasu imu-padawa awọn ẹbun Ẹmi, bibọ Kristi ati gbogbo nkan wọnyi, jẹ ki o di ẹni ifibu. Bi o ba gbiyanju lati mu ọkan ninu Ọrọ yii, ki o si sọ wipe, wọn ko si fun ọjọ oni, tabi ti o fun un ni itumọ miran ti wọn kọ ninu ile-iwe ẹsin kan, jẹ ki o di ẹni ifibu.

66 Jẹ ki a ka a siwaju, wo bi Paulu ṣe rii gba, ki o ri ohun ti mo ngbiyanju lati sọ fun yin lowurọ yii:

Njẹ nisisiyi, eniyan ni emi nyi lọkan pada tabi Ọlọrun? Tabi eniyan ni emi nfẹ lati wu? Nitoripe bi emi ba si nwu eniyan, emi ki yoo le ṣe iransẹ Kristi.

Bawo ni mo ṣe le e reti ohun miran, bawo ni ẹnikan to fẹran Ọlọrun, paapa oniwaasu ṣe le e se ohunkohun ki awọn eniyan ma korira rẹ? Awọn eniyan yoo korira rẹ. Jesu wipe. “Bi wọn ba pe Emi olori ile, Emi si ni Oluwa to ga ju gbogbo eniyan lọ. Emi ni mo lee ṣe iṣẹ iyanu julọ, ti mo ni Ẹmi Mimọ ju gbogbo yin nitoripe, mo ni ẹkunrẹrẹ Rẹ ninu Mi. Bi wọn ba si pe mi ni Belsebubu, melomelo ni wọn yoo pe ẹyin?” O si wipe, “Ẹ maṣe daniyan lọkan yin nipa ohun ti ẹ o sọ, nitori kii ṣe ẹyin ni yoo sọrọ. Yoo jẹ Baba ti ngbenu yin, ni yoo sọrọ lakoko naa. Iwọ saa ti duro ti ọrọ naa”. Nigbati o si pari kikọ Iwe naa, O wipe, “Ẹnikẹni ti o ba mu ẹyọ ọrọ kan kuro ninu iwe yii, tabi ti o fi ọrọ kan kun un, oun ni a o yọ orukọ rẹ kuro ninu iwe iye.” Ki Ọlọrun ran wa lọwọ lati duro tii.

67 Ẹsẹ ti o kan bayi, jẹ ki ntete ka a:

Sugbọn ara, mo fẹ ki ẹ mọ pe ihinrere ti mo waasu ki iṣe nipa ti eniyan. (Bayi, emi kii ṣe Methodisti, Baptisti, Presibiteria tabi Pẹntikosita. Kii ṣe ti eniyan)

Nitori kii ṣe lọwọ eniyan ni mo ti gba a, bẹẹ ni a ko fi kọ mi.

“Emi ko gba a lọwọ eniyan, ko si ile ẹkọ ẹsin kan, ko si ọmọwe kan, ẹkọ eṣin kan, ile iwe kan. Emi ko gba a ni ọna yẹn, a ko kọ mi ni ọna yẹn, emi ko gba a ni ọna yẹn, ko si tọ mi wa ni ọna yẹn” Bawo ni o ṣe wa, Paulu?

……Sugbọn nipa ifihan Jesu Kristi.

Nigbati Kristi fi ara Rẹ han fun mi, wipe Oun ni Ọmọ Ọlọrun, nigbati Ọwọn Ina yẹn wa sori mi lọjọ yẹn. Mo wipe, “Ta ni iwọ, Oluwa?” O wipe, “Emi ni Jesu.”

68 Mo fẹ fihan ọ, ohun ti o ṣẹlẹ si i. Nisisiyi, bi ẹnikan ba ni iriri kan, wọn yoo fẹ ki o fi ọdun mẹwa kọ ede Giriki, ati ọdun mẹwa si lati kọ ohun miran, ki o si to ṣe iyẹn tan, ina rẹ ti ku tan. Wo o:

Nitori kii ṣe lọwọ eniyan ni mo ti gba a, bẹẹ ni, a ko fi kọ mi, sugbọn nipa ifihan Jesu Kristi.

Nitori ẹyin ti gburo iwa-aye mi nigba atijọ ninu isin awọn Juu……

“Mo jẹ ọmọwe nla kan. Ah, mo ni in”. A kọ ọ labẹ Gamaliẹli, ti iṣe olukọni to ga julọ nilẹ awọn Juu. Awọn melo ni o mọ wipe Gamaliẹli jẹ ọkan ninu awọn Olukọni to ga julọ? Bẹẹ ni, sa. “Ninu ẹsin Juu, ah, wọn da mi mọ. Mo mọ gbogbo rẹ daju, bi a ṣe nka ijẹwọ igbagbọ ati ohun gbogbo wọn ni. Mo mọ bi a ṣe nṣe adura aarọ ati bibukun awọn eniyan”.

Bi mo ti ṣe inunibini si ijọ eniyan Ọlọrun rẹkọja aala, ti mo siba a jẹ. (Bi mo ṣe gbiyanju lati da awọn eniyan agba-were-mẹsin yẹn duro)

Mo si ta ọpọlọpọ awọn ẹlẹgbẹ mi yọ ninu isin Juu,

“Mo jẹ ẹni nla kan. Mo ta wọn yọ, mo fihan wọn pe mo lee pa ijọ lẹnu mọ, nitori mo pa stefanu, mo si ṣe ọpọ nkan miran. Wo bi mo ti ṣe to. ”Bi oun ṣe ṣe inunibini rekọja.

69 Mo ta ọpọlọpọ awọn ẹlẹgbẹ mi yọ ni orilẹ-ede mi, nitoripe mo nitara rekọja si ofin atọwọdọwọ awọn baba mi.

Ranti bayi, kii ṣe Ọrọ Ọlọrun. Sugbọn “ofin atọwọdọwọ ti awọn baba.” Asa ijọ niyẹn. Ẹyin wipe, “Mo ti jẹ Mẹthọdosti patapata mo jẹ Baptisti de gongo, mo jẹ Pẹntikọsita de gongo” Ah, ṣe bẹẹ ni? Ẹmi fẹ jẹ ti Ọlọrun de gongo. Ohun niyẹn. O dara.

…..ofin atọwọdọwọ awọn baba mi.

Sugbọn nigbati o wu Ọlọrun ẹniti o ya mi sọtọ lati inu iya mi wa, ti o si pe mi nipa oore-ọfẹ Rẹ.

Lati fi ọmọ Rẹ han ninu mi,

Bawo ni iyẹn? “Ẹmi Mimọ ninu mi. O wu Ọlọrun lati mu mi, ẹniti o ti ya mi sọtọ lati inu iya mi, o si fun mi ni ọmọ Rẹ, tii ṣe Ẹmi Mimọ gẹgẹbi Ẹmi ninu mi, lati fi ara Rẹ han ninu mi” Àh áh, àh! Mo fẹ kigbe soke diẹ bayi.

70 Wo o, jẹ ki nsọ fun ọ, arakunrin. Nigba ti o wu Ọlọrun! Ah, Halleluyah. Nigbati o wu Ọlọrun! Baba kan ti o jẹ ọmuti. Ati Iya kan (Ki Ọlọrun bukun ọ mama mi, emi ko sọ ohun kan lodi si ọ) Sugbọn iya ti ko mọ ohunkohun nipa Ọlọrun. Ati baba kan to nmuti yo, to si sun soju titi. Ti a ko ni bata lẹsẹ lati lọ sile iwe, ti irun gun lori mi kan ọrun mi, gbogbo eniyan si korira mi nitori pe, mo jẹ ara Kentucky ni ipinlẹ Indiana nibi. Ah, o si jẹ ifarahan to buru jai. Sugbọn, o wu Ọlọrun! Amin! O wu Ọlọrun ẹniti o mu mi jade lati inu iya mi, ki o le e fi ọmọ Rẹ han ninu mi, nipa siṣe mi ni Oniwaasu Ọrọ Rẹ, ti yoo duro ti Ọrọ naa patapata ti yoo ri iran, isẹ ami ati isẹ ara.

71 Ṣe o ri ohun ti Paulu nsọrọ nipa rẹ? O wu Ọlọrun lati ṣe iyẹn. Fetisilẹ daradara. Ẹsẹ kẹrindinlogun:

Lati fi Ọmọ Rẹ han ninu mi, ki emi lee maa waasu Rẹ laarin awọn keferi. Lojukanna, emi ko ba ara ati ẹjẹ gbimọ pọ. (Emi ko ba Ijọ sọrọ)

Emi ko lọ ba bisọbu kankan lati beere ohun ti mo nilati ṣe. Emi ko lọ ba eniyan ẹlẹran ara kan, tabi ẹgbẹ eniyan ẹlẹsin kan. Emi ko ni ohun kan I ṣe pẹlu wọn Emi ko ba eniyan kankan gbimọ pọ. Bẹẹ ni emi ko lọ si Jerusalẹmu lati lọ ba awọn alufaa mimọ ati awọn baba mimọ, lati sọ pe, “Wo o, mo ma ri iran kan. Kinni mo nilati ṣe nipa rẹ? Mo ri Jesu Oluwa Olubukun ninu iran” “Wọn I ba ti sọ wipe, Iwọ kuro nibi yii, iwọ agbawere-mẹsin yii, kin ni o ṣẹlẹ si ọ gan? Rara, mo ti ni gbogbo oye ẹkọ wọn ṣaaju”.

72 Mo lee fihan ọ ninu Iwe Mimọ, Paulu wipe, oun nilati gbagbe gbogbo ohun ti o ti tẹlẹ, ki o ka wọn si asan, ki o lee mọ Kristi. Ah!

Bẹẹ ni, emi ko goke lọ si Jerusalẹmu tọ awọn tii ṣe Aposteli ṣaaju mi, sugbọn mo lọ si Arabia, mo si tun pada wa si Damasku.

Lẹyin ọdun mẹta, nigba naa ni mo goke lọ si Jerusalẹmu lati lọ ki Peteru, mo si gbe ọdọ rẹ ni ijọ mẹẹdogun.

Bi a si ti n ka lọ, a rii wipe, oun ati Aposteli Peteru ko ri ara wọn ri laye, wọn ko mọ ara wọn, sugbọn nigbati wọn pade, wọn nwaasu otitọ kan naa! Ọlọrun ni ile iwe tirẹ. Bẹẹ ni.

73 A ri Peteru lọjọ Pẹntikọsti, o wipe, “Ronupiwada, olukuluku yin, ki ẹ si ṣe itẹbọmi ni orukọ Jesu Kristi fun imukuro ẹsẹ yin, ẹyin yoo si gba ẹbun Ẹmi Mimọ”

Filipi wipe, “Ah, eyi logo pupọ! Emi pẹlu nilati ṣe ohun kan. Mo ni ipe kan lati lọ si Samaria”. O jade lọ sibẹ. O si bẹrẹ si jẹri laarin ilu. Ohun kinni, alaisan kan wa. O gbe ọwọ lee, alaisan si ni imularada, o ntọ soke, o nyọ. O bẹrẹ si ni isọji nla. O wipe, “Ogo ni fun Ọlọrun, awa niyi” O bẹrẹ si ni isọji nla. O wipe, “Gbogbo yin lo nilo Ẹmi Mimọ”. O wipe “Ohun ti ẹ nilati ṣe ni ki a baptisti yin lorukọ Jesu” Nitori naa, O mu gbogbo wọn, o si ṣe itẹbọmi fun wọn ni Orukọ Jesu. O wipe, “Peteru maa bọ, wa gbe ọwọ le wọn”. Wọn si gba Ẹmi Mimọ.

Peteru lọ sile Kọniliu, o si ri bẹẹ gẹgẹ.

74 Paulu ko tilẹ ti i ri i rara, tabi gbọ iwaasu rẹ, sugbọn o ngba igberiko Efesu kọja, o si ri awọn ọmọ ẹhin kan nibẹ. O ri oniwaasu Baptisti kan - tii ṣe Apolo agbẹjẹro kan to gbagbọ, ẹniti o jafafa, to ni ọpọlọ, to nfi

Majẹmu laelae ṣe idaniloju pe Jesu ni Ọmọ Ọlọrun. Bẹẹ ni sa. Ọkunrin to jafafa ni. Awọn eniyan si npariwo ayọ. Bibeli sọ bẹẹ. Iwọ ka Iṣe Awọn Aposteli, ori kejidinlogun ati ikọkandinlogun. Wọn nni ayọ, wọn njo ninu Ẹmi, wọn si nsare kiri pẹlu ayọ. Paulu wipe, “Sugbọn njẹ ẹyin ti gba Ẹmi Mimọ lati igba ti ẹ ti gbagbọ bi?

75 Ati si ẹyin Baptisti ti ẹ n gbiyanju lati mu awọn eniyan gbagbọ pe Giriki rẹ wipe ṣe ẹyin ti gba Ẹmi Mimọ nigbati ẹ gbagbọ? Mo pe yin nija, ki ẹ wa fi Giriki naa han mi. Mo ni ojulowo Giriki lọwọ. Mo ni Aramaiki pẹlu, mo ni Heberu pẹlu. Olukuluku wọn ni o sọ wipe, “Ṣe ẹyin ti gba Ẹmi Mimọ lẹyin ti ẹ ti gbagbọ?”

Nipa igbagbọ ni a gba ọ la. Iyẹn ni igbagbọ rẹ ninu Ọlọrun. Ẹjẹ naa pa ọ mọ ni mimọ kuro ninu ẹṣẹ, nitoripe o ṣe irubọ kan. Ẹjẹ ko gba ọ la, ẹjẹ pa ọ mọ ni mimọ. Ati nipa Ẹmi kan, ni a baptisi rẹ sinu Ẹmi Mimọ, sinu idapọ awọn onigbagbọ, ati sinu idapọ ti Ẹmi Mimọ, lati dari rẹ nipa ti Ẹmi lati maa ṣe iṣẹ ami ati isẹ ara.

76 Duro, a nduro de ohun kan. (Bi o ba ṣe diẹ si, a o de ibẹ. Mo lero pe yoo ye wa. Mo sọ pe ki ẹ pe mi ni akoko yii, abi bẹẹ kọ? O sa ṣẹlẹ pe mo wo agogo yẹn. O ku ọrọ kan tabi meji si, o ku diẹ)

77 Bawo ni igbala yii ṣe npẹ to? Titi di igba wo ni? Iru igbala wo ni? Lati ijọ de ijọ? Jẹ ki a ṣi si Heberu 9:11, fun iṣẹju kan, lati wo bi o ṣe pẹ to. Ṣi si iwe Heberu jẹ ki a ri bi igbala yii ṣe wa pẹ to, wo iru igbala ti o jẹ. Jẹ ki a ka Heberu 9:11.

Sugbọn nigbati Kristi de bi Olori Alufa awọn ohun rere ti nbọ nipasẹ agọ ti o tobi ti o si pe ju ti iṣaaju lọ eyiti a ko fi ọwọ kọ, eyini ni, ti kii ṣe ti ẹda yii.

Bẹẹ ni kii ṣe nipasẹ ẹjẹ ewurẹ ati awọ maluu, sugbọn nipa ẹjẹ oun tikararẹ, o wọ ibi mimọ lọ lẹẹkan ṣoṣo, (Nigba melo ni? Lẹẹkan-ṣoṣo!) lẹhin ti o ti ri idande gba [ṣe igbala fun ọsẹ kan, igbala titi di isọji ti nbọ? Iru wo ni?] O ti gba idande ainipẹkun fun wa.

78 Kin ni ọrọ yii, “ainipẹkun” tumọ si? Ninu Kristi, lẹhin ti mo ti gbagbọ…Ko si ẹniti o le pe Jesu ni Kristi lai ṣe nipa Ẹmi Mimọ. Ẹgbẹ awọn eniyan mẹta ni o wa; alaigbagbọ, alafẹnujẹ onigbagbọ ati onigbagbọ. Sugbọn awọn ti o ti gbagbọ si Iye ainipẹkun, ti wọle si ibi mimọ julọ.

Wo agọ ti atijọ naa. Kinni ohun kinni ti o ṣe? O wọ inu gbọngan ti awọn keferi. Ipele ti o kan ni pẹpẹ idẹ, nibiti wọn ti nwẹ ẹran irubọ naa ninu agbada idẹ. Eyi ti o kan ni pipa irubọ naa ati fifi ẹjẹ rẹ wọn pẹpẹ naa. Lẹyin naa, Aroni, lẹẹkan lọdun ti a ta ororo le pẹlu kinni? Pẹlu ododo ti ṣaroni, ororo iyebiye ti o ni oorun didun ninu rẹ. Wọn da a lee lori, o si san lọ titi de iṣẹti aṣọ rẹ. Wo o bi ọkunrin yii ṣe nilati lọ sinu aṣọ ikele ni igba kan lọdun, ti yoo gbe ẹjẹ niwaju rẹ lọ si itẹ aanu. O si mu ọpa rẹ lọ sibẹ lọdun kan, o gbagbe rẹ. Nigbati wọn pada lọ mu un, o ti ruwe, o si ti tanna - ọpa igi to ti gbẹ fun ọpọlọpọ ọdun ninu aginju ti wọn fi si ibi mimọ. Kiyesi I, nigbati wọn mu ẹjẹ majẹmu naa, a tami ororo lee. O si ni aṣọ ti o wọ, ti a so awọn agogo mọ, Pomegreneti kan ati agogo saworo. Ọkunrin naa si nilati rin ni ọna kan pato, bi o ṣe ngbe ẹsẹ ti o nrin, awọn agogo yẹn yoo ma a kọrin wipe, Mimọ, Mimọ, Mimọ, si Oluwa. Mimọ, Mimọ, Mimọ, si Oluwa. Mimọ, Mimọ, Mimọ si Oluwa. Ah ah!

79 Ki ni mo nsọrọ nipa rẹ? Gbọ, agọ ile isin Branham, Ẹ ti ni anfani yin! Nigbati a ba ti fi Ẹmi mimọ kun ẹnikan lati ni isọdọmọ sinu ẹbi Ọlọrun, ki Baba le fi sipo iṣẹ lati wa loju iṣẹ nita lọhun, fun erongba Ọlọrun tabi ohun ti Ọlọrun ti pe e fun, irin rẹ nilati jẹ mimọ mimọ, mimọ si Oluwa! Mimọ, Mimọ, Mimọ si Oluwa!“

“Ah, o nilati yi pada si ohun yii”.

“Mimọ, Mimọ, Mimọ, si Oluwa”

“Ah, iwọ nilati gba ohun ti awọn alagba sọ gbọ”

Sugbọn “Mimọ, Mimọ, Mimọ, si Oluwa” Jẹ ki Ọrọ Rẹ jẹ akọkọ. Jẹ ki o jẹ ohun gbogbo ti o wa, ki o si kalẹ ninu ọkan rẹ! Irin rẹ gbọdọ wa ninu Ọrọ naa. “Mimọ, Mimọ, Mimọ, si I Oluwa”

“Ah, Bi iwọ ba le e wa si ibi yii, mo nsọ fun ọ ohun ti a o ṣe. A o ṣe ẹgbẹ ẹsin nla kan, a o si fi ọ sinu ẹgbẹ ẹlẹsin wa, iwọ yoo jẹ ẹni nla kan”

Mimọ Mimọ, Mimọ si Oluwa. “Mimọ, Mimọ, Mimọ, si Oluwa” Iwọ ntẹsiwaju. Ko ṣe Pataki ohun ti ẹnikẹni le sọ!

Wọn wipe, “Da awọn fọnran iwaasu rẹ pada, ṣe bayi ṣe iyẹn ṣe omiran”

“Mimọ, Mimọ, Mimọ si Oluwa” Iwọ ti gbe oju rẹ si Kalfari. Ko si si ohun kan ti yoo da ọ lẹkun! Irin igbe aye rẹ gan, iwọ nrin loju popo ti Ọba naa, ti a fi ororo itami-ororo le ọ, ti iwọ nrin lọ ninu ibi Mimọ julọ. Ah ah! Amin! O dara.

80 Paulu wipe, oun ko gba otitọ naa lati ọdọ ọwọ eniyan. Kin ni o sọ bayi? (A pada si ẹkọ wa ni Efesu) Nigba ti o ti sọ di mímọ̀ fun wa, ohun ijinlẹ ifẹ Rẹ“. Kin ni ifẹ Rẹ? ”Sọ ijinlẹ ifẹ Rẹ di mímọ̀“ Iwọ ti o nkọ ọ silẹ, ẹsẹ ikẹsan. (Bayi mo nilati yara kankan, a ti npẹ ju).

Ah, ọrọ kọọkan jẹ ẹsẹ wura. Iwọ sa le mu u, ki o sa maa dan an si. Iwọ si le mu ọrọ kan nibi, ki o mu lọ si Jẹnẹsisi lati fẹ ẹ loju, ki o tun mu lọ si Eksodu lati fẹ ẹ loju, ki o mu u lọ si Lefitiku ki o tun fẹ ẹ loju, nigbati iwọ ba si de Ifihan gbogbo rẹ lati ibẹrẹ de opin tumọ si Jesu! Amin. Iwọ saa le e tọpinpin rẹ to bi o ba ṣe fẹ, yoo si jẹ Jesu nigbati o ba de Ifihan! Nitori O wipe, Emi ni Ẹniti O ti wa, ti O si wa, ti yoo si wa. Emi ni Gbongbo ati Iru Ọmọ Dafidi, Irawọ Owurọ. Emi ni Alfa, ati Omega. Iyẹn ni 'A' ati 'Z' ninu ABD ti Giriki “Emi ni lati A de Z, Emi ni gbogbo rẹ”. Bẹẹni “Emi ni o wa laaye, ti o si ku ti O si wa laaye titi lae. Mo ni kọkọrọ iku ati isa oku.” Ah, ah! Gbogbo koko ọrọ ti o ba mu nibi yii, ti o si tọpinpin rẹ, yoo pari si Jesu.

81 (Lẹyin igba diẹ si, a o danu duro) Kin ni a n duro fun? Kin-ni a n pade fun? Kin ni erongba rẹ? Kin ni aye nkerora fun? Kin ni awọn ado oloro nduro de? Kin ni gbogbo nkan nduro de?

Ṣi si Romu, ori kẹjọ fun iṣẹju kan. Kin ni a nduro de? Kin ni gbogbo nkan wọnyi nduro de? Kin ni akoko sọ? Romu, ori kẹjọ, ẹ jẹ ki a bẹrẹ kika lati ẹsẹ kọkandinlogun, ki a si ka a nibiyi, lati mu ki o dun gan an. Ẹ jẹ ki a bẹrẹ lati ẹsẹ kejidinlogun. Ẹ sa jẹ ka bẹrẹ lati ẹsẹ kẹrinla.

Nitori iye awọn ti a nṣe amọna fun lati ọdọ Ẹmi Ọlọrun wa, awọn naa ni iṣe Ọmọ Ọlọrun.

Nitori ẹyin ko tun gba ẹmi ẹru lati maa bẹru mọ, sugbọn ẹyin ti gba ẹmi Isọdọmọ nipa eyi ti awa fi nke pe Abba, Baba.

82 Wọn ma a nsọ pe, “Ha, ṣe emi yoo lee duro bayi, oooo, bi mo ba sa le e duro laiyẹsẹ, laiṣubu.” Ki iṣe emi ni mo ndi igbagbọ mu rara! Ki i ṣe boya mo le e di igbagbọ mu laiṣubu, ohun to ṣe pataki ni pe, njẹ Ọlọrun di mi mu. Emi wa ninu Rẹ nisisiyi.

Bayi, ẹyin ọmọ ijọ Prẹsibiteria wipe, “Ah, awa ti gba iyẹn gbọ tẹlẹ.” Sugbọn igbe aye rẹ fihan pe ko ri bẹẹ, ayafi bi iwọ ba gbe iru igbe aye ti oun gbe, ti iwọ si gba ihinrere kan naa ti oun waasu gbọ.

Iwọ wipe, “Awa Baptisti gbagbọ ninu ipamọ ainipẹkun fun onigbagbọ.” Ẹyin si jade lọ ẹ mu siga, ẹ nlọ sile ijo, ẹyin obinrin nge irun yin, ẹ nkun oju yin ni ọda, ẹ si nwu iwakiwa? Eso aye yin fihan pe ẹ ko gba a gbọ.

Nigbati mo wipe, “Ṣe iwọ gbagbọ ninu iwosan lai-lo-oogun?”

Iwọ wipe, “Ọmọwe Jones sọ bẹẹ, o sọ wipe o ti ṣẹlẹ ri ni igba kan to ti kọja”

Iwọ alagba-gebe! Kin ni o ṣe ọ gan? Iwọ ọmọ ti a ti tanjẹ. Iwọ jinna si ihinrere pupọ, to bẹẹ ti o ṣe ni laanu. Iwọ ti ṣina si opopo abata kan lori akitan to njo kan. Ṣe iwọ ko ri ohun ti o sọ nibi yii ni? Wipe gbogbo ẹmi to ba jẹwọ wipe Jesu ko wa ninu ara lọwọlọwọ bayi jẹ ẹmi to kuna. Bibeli wipe Jesu Kristi jẹ ọkan naa lana, loni ati titi lae. Ohun ti O sọ ni pe, Oun ti O jẹ nigba yẹn, ni O jẹ nisisiyi, bẹẹ si ni titi lae. Sa fetisilẹ.

83 Nitori ẹyin ko tun gba ẹmi ibẹru lati ma a bẹru mọ. Sugbọn ẹyin ti gba ẹmi isọdọmọ.

Bayi lẹyin ti a ti sọ ọ dọmọ, o dara. Nigbati a sọ ọ dọmọ, a fi ọ sipo, nigba naa o ye ọ - lẹyin aṣeyẹ naa, a ti fi ọ si ipo naa bi o ti yẹ. Ọmọ ni ọ, nigbati a tun ọ bi. Ibi rẹ niyẹn. Sugbọn nisisiyi a ti fi ọ sipo.

Awa ko gba ẹmi ibẹru, sugbọn a ti gba ẹmi isọdọmọ nipa ẹyiti awa fi nke pe, Abba, Baba (ti o tumọ si “Ọlọrun mi”. O dara)

Ẹmi tikararẹ ni o nba ẹmi wa jẹri pe, ọmọ Ọlọrun ni awa iṣe.

Bawo lo ṣe nṣe e? Iwọ wipe, “Ogo ni f'Ọlọrun, Halleluya! Iyẹn ko dami laamu, ọmọ Ọlọrun ni mi, o si jade lọ ṣe ohun ti iwọ nṣe? Ẹmi Ọlọrun yoo ṣe iṣẹ Ọlọrun.

Jesu wipe, “Ẹniti o ba gbagbọ ninu Mi, isẹ ti Emi nṣe ni oun pẹlu yoo ṣe”. Ṣe o rii.

84 Bi ajara yii ba jade wa ti o si so eso girepu, ti ẹka miran si jade wa ti o so apiroko, ohun kan kuna. Ṣe o rii, ijọ tí wọ́n lọ́ si ara ijọ tootọ nì, ẹka kan ti a lọ́ ni, ẹnikan ti a lọ́ ni. Bi ẹnikan ti o jẹ ọmọ-ijọ-ẹlẹkọ-adamọ kan ba si pe ara rẹ ni Kristẹni, ti ko si ni Ẹmi Mimọ, ti ko ni agbara Ọlọrun, ẹka lilọ kan lasan ni.

85 Bayi, bi iwọ ba jade lọ, ti o si ṣe bi awọn wọnyi ti ṣe, ti o fede miran sọrọ, emi ti ri awọn ẹmi eṣu, ti wọn fede miran sọrọ. Bẹẹ ni. Mo ti ri wọn ti wọn jo ninu ẹmi, ti wọn kigbe, ti wọn si ru ni ẹnu ati ohun gbogbo bẹẹ. Mo ti ri iyẹn. Emi ko sọrọ nipa iyẹn. Mo n sọrọ nipa Ẹmi Ọlọrun.

Ẹmi tikalarẹ ni o nba ẹmi wa jẹri pe, ọmọ Ọlọrun ni awa iṣe:

Bi awa ba si jẹ ọmọ, njẹ ajogun ni awa, ajogun Ọlọrun, ati ajumọ-jogun pẹlu Kristi, bi o ba ṣe pe awa ba a jiya, ki a si le ṣe wa logo pẹlu rẹ.

Nitori mo siro rẹ pe, iya isisiyi…..

Sa feti si eleyi. Ah, eyi ma dara o!

Nitori mo siro rẹ pe, iya igba isisiyi ko yẹ lati fi ṣe akawe ogo ti a o fihan ninu wa.

Nitori ifojusọna ti ẹda nduro de ifihan awọn ọmọ Ọlọrun.

O pe ọrọ kan nibi yii. Ni ede Girirki o jasi, "awọn ifojusọna gbogbo ẹda", ẹda nduro, o nfojusọna fun ifarahan-fayeri ti awọn ọmọ Ọlọrun.

86 Kin ni ohun gbogbo n duro de? Kin ni gbogbo ẹda nduro de? Ifarahan-fayeri ti awọn Ọmọ Ọlọrun. O nduro fun ijọ lati wa si ipo rẹ. Ta ni Ọmọ Ọlọrun ni ipilẹṣẹ? Adamu. Nibo ni ilẹ ijọba rẹ? Gbogbo aye. O ni isakoso lori aye. Ṣe otitọ niyẹn? Ọlọrun ki i ṣe Ẹniti o dawa ni Oun nikan mọ, O ti di Jehofa. Eyi ni pe, 'Emi ni Ọlọrun, Mo si ti da ohun kan to kere si Mi, ti wọn wa labẹ Mi. Mo si ti fun wọn ni agbara isakoso ati ilẹ ijọba. Ilẹ ijọba ti o wa labẹ isakoso wọn si ni aye." Ẹniyan ni isakoso lori aye. Gbogbo ẹda si nduro de awọn Ọmọ Ọlọrun lati farahan-fayeri.

Awa nwọna fun bibọ ẹgbẹrun ọdun naa

Nigbati Oluwa yoo wa mu Iyawo lọ sile

Ah, aye nkerora, wọn nkigbe fun ọjọ itusilẹ naa,

Nigba ti Oluwa wa yoo pada wa saye.

87 Sẹ bẹẹ ni? Diduro. Ọlọrun ngbiyanju lati fi Ijọ Rẹ si ipo, lati fi ara Rẹ han, o nwa ẹnikan ti oun le e siṣẹ ninu rẹ, ti yoo sọ pe "Ẹmi mi niyẹn, to nsisẹ pẹlu ominira, ohun niyẹn, Mo lee siṣẹ nibi yii". O tun ri ẹlomiran nibomiran ti o fi sipo isẹ; "Mo lee fi sipo." Isọdọmọ, ti i ṣe ifinisipo, ifarahan-fayeri. Yoo mu un jade lọ si ibikan, yoo si ṣe aṣeyẹ kan fun un, yoo fi angẹli kan bẹẹ wo, lati sọ ohun kan fun un. Bayi, o ti sọ otitọ. Bi o ba kan ṣe agbelẹrọ kan, ko ni siṣẹ. Rara, rara, ko le e siṣẹ. A ti ni ọpọlọpọ iyẹn. Sugbọn ohun ti mo nsọ ni ifarahan-fayeri awọn ọmọ Ọlọrun, nigbati Ọlọrun ba fi ara Rẹ han, ti o si ran an jade. Nigba naa ni o jade lọ, ohun ti o si sọ jẹ otitọ, Ohun ti o ṣe jẹ otitọ. Oun si fi Kristi han nipa isẹ rẹ. Bawo ni o ṣe le da a mọ? Nipa ọna ti o fi duro ti Ọrọ naa. Bi a ṣe nmọ gbogbo eniyan niyẹn, o jẹ bi o ba ṣe duro ti Ọrọ naa. "Bi wọn ko ba sọrọ ni ibamu pẹlu Ọrọ naa, ko si iye ninu wọn" bẹẹ ni Bibeli sọ. Fi wọn silẹ.

88 Bayi, jẹ ki a ka, lẹyin naa, a nilati danu duro, nitoripe, akoko wa ti nlọ. O dara, lati ẹsẹ kẹsan:

Ẹniti o ti sọ ohun ijinlẹ ifẹ rẹ di mimọ fun wa, gẹgẹ bi idunnu rẹ, ẹyiti o ti pinnu ninu rẹ.

O ti pinnu eleyi ninu Rẹ, ṣaaju ipilẹṣẹ aye. Ẹni melo ni o loye rẹ?

Fun isẹ iriju ti kikun akoko naa, ki o lee ko ohun gbogbo jọ ninu Kristi…..

Ah ah, ah. A tun ti de bayi! Ah, jẹ ki a re e kọja

…..Sá à a ti kíkún akoko.

89 Ṣe iwọ gbagbọ pe saa ti akoko wa? Bibeli sọ bẹẹ. "Ni saa ti ẹkunrẹrẹ akoko" Kin ni ẹkunrẹrẹ akoko? O dara, akoko ti ofin Mose ti wa. akoko ti ofin Johanu Onitẹbọmi wa. Saa ti Kristi ti wa. Akoko ti ẹgbẹ-ijọ-to-feniyan-sadari ti wa. Akoko ti itujade Ẹmi Mimọ ti wa. Eyi si ni akoko ti isọdọmọ, ohun ti aye duro de, to nkerora lati ri. Nigbati ẹkunrẹrẹ akoko ba si de…. Kin ni ẹkunrẹrẹ akoko? Nigbati awọn ti awọn oku yoo jinde, ti aisan dẹkun, nigbati aye ba dẹkun ikerora - ẹkunrẹrẹ saa ti akoko. Kiyesi eleyi:

Fun isẹ iriju ti ẹkunrẹrẹ akoko naa, ki o lee si ohun gbogbo jọ ninu Kristi.

Ṣe inu rẹ ko dun bi? Bawo ni yoo ṣe ṣe e? Yoo ko ohun gbogbo sinu tani? (Ipejọpọ wipe, "Kristi") Bawo ni mo ṣe le de inu Kristi (Nipa Ẹmi kan) Nipa Ẹmi kan ni a baptisi gbogbo wa sinu (Ara ka) ara kan. Ara naa si jẹ ara tani? ("Kristi") Ara ti a ti da lẹjọ na. O gba idajọ wa. Nigba naa, kin ni a jẹ? "Nigba ti Emi ba ri ẹjẹ naa, Emi yoo re ọ kọja" Ni gbogbo igba ti O ba si wo ara naa, O rii ti o kun fun ẹjẹ. Bawo ni mo si ṣe wọ inu Rẹ? Nipa Ẹmi Mimọ. Oun yoo re e kọja. Àh, áh, àh!

Fun isẹ iriju ti ẹkun akoko naa, ki o lee ko ohun gbogbo sọkan ninu Kristi, iba ṣe ẹyiti mbẹ ninu awọn

ọrun, tabi ẹyiti mbẹ ni aye, ani ninu Rẹ:

90 Bi iwọ ba fẹ sọrọ nipa orukọ kan, a o bẹrẹ lori rẹ nisisiyi fun igba diẹ. Gbogbo ẹbi ti o wa ni ọrun ni a npe ni kin ni? (Apejọpọ Wipe, “Jesu Kristi”) Gbogbo ẹbi ti aye ni a npe ni? (“Jesu Kristi”)

Awọn obinrin rere kan wa nibi yii, awọn obinrin to dara gidi. Ọkan ṣoṣo ni iya-aafin William Branham. Oun ni iyawo mi. Oun lo nlọ sile pẹlu mi. Ṣe o rii, awọn toku nlọ sile pẹlu ọkọ tiwọn.

Ijọ nla kan lo wa laaye tii ṣe ti Ọlọrun alaaye. O njẹ orukọ Rẹ. A kun un pẹlu Ẹmi Rẹ. Otitọ niyẹn.

91 Emi ko da iṣẹ rere wọn lẹbi, emi ko da ile-itọju-alaisan ti wọn kọ lẹbi, ati awọn ohun rere ti wọn ṣe. Mo ro pe wọn dara pupọ, wọn si jẹ ibukun fun awọn talaka, ati awọn eniyan to njiya. Emi ko da a lẹbi, gbogbo awọn ohun rere miran wọnyi ti wọn nṣe. O dara, iyẹn tọ. Ati gbogbo igbekalẹ wọn ti wọn fi awọn miliọnu dọla ṣe, o kuku san ki nri iwọnyẹn ju gbogbo ile ọtin ti o wa lọ nigba-kii-gba. Mo bu ọla fun wọn gẹgẹbi iransẹ Ọlọrun to nduro nibi aga iwaasu.

Sugbọn nigbati a ba nsọ nipa ikojọpọ ni opin saa akoko, yoo duro de ifarahan ti awọn ọmọ Ọlọrun. Ninu saa yẹn, ki o le ko gbogbo awọn ti a ti mu wa sinu Kristi jọ. Kin ni Kristi? Bawo ni a ṣe nwọ inu Rẹ? “Kọrinti Kinni 12.” Nipa Ẹmi kan, ni a baptisi gbogbo wa sinu ara kan“ ti i ṣe ara Kristi, a si ti mu wa jẹ alabapin gbogbo ẹbun ati ohun gbogbo ti o ni. Ṣe otitọ ni? Gbogbo aye si nkerora, wọn nke, wọn nduro de ifarahan nigba ti Kristi ati ijọ rẹ yoo di ọkan papọ.

Fun isẹ iriju ti kikun akoko naa, ki O lee ko ohun gbogbo jọ ninu Kristi, iba ṣe eyiti nbẹ ninu awọn ọrun, tabi eyiti nbẹ ni aye, ani ninu Rẹ.

Ninu Ẹniti ti gba ini Rẹ pẹlu…..

92 Ah, Arakunrin Neville, dariji mi fun gbigba akoko yii. Ọrọ yẹn, “Ogun Ini” Ah ah! O dabi ibatan ẹni. Mo lero pe ori mi ko daru. Emi ko ro bẹẹ. Sugbọn kin ni ogun Ini? Awa ti gba ogun Ini kan. Ẹnikan nilati fi ohun kan silẹ fun ọ. Ọlọrun, ṣaaju ipilẹṣẹ aye fi ohun kan silẹ fun ọ. Orukọ kan ti a ti kọ sinu Iwe kan, pe nigbati a ba pa Ọdọ-Aguntan naa, a o da ọ mọ pẹlu Rẹ. Ah! Jẹ ki a fi iyẹn silẹ di alẹ yii. Jẹ ki a sa a ka siwaju si. Ah ah! Bawo ni a o ṣe de ori kẹta lalẹ yii? A ko tilẹ tii pari ẹsẹ mẹrin tabi marun ninu eleyi. Bayi, a ti nmura lati danuduro. Emi yoo sa ka a, n o si fi silẹ.

93 Ninu Ẹniti awa ti gba ogun ini kan

Kin ni? Bawo ni a ṣe ri ogun ini yii gba? Bawo ni a ṣe rii gba? Ṣe nitoripe awa rin ni ododo ni? Bawo ni a ṣe ri ogun ini naa gba? Nitoripe a ti yan wa tẹlẹ. Amin. Ah ah! Ẹyin arakunrin mi ti Arminia, mo mọ pe eyi le fun yin. Emi ko fẹ ṣẹ̀ yin, sugbọn inu mi dun pupọ lati mọ eleyi. Iwọ ti gba a, arakunrin. O dara. Ko kan ye ọ ni. Sibẹ iwọ ti rii gba. O dara. Iwọ tọ. Sugbọn o dara pupọ lati wo otitọ yẹn. O dabi ohun ti Arakunrin Neville sọ nipa ile itaja nla kan ni ana. “Lọ gbe akasọ ki o si wo yika, nibi gbogbo, ohun ti iwọ ni.” Bẹẹ ni, sa. Kin ni iyẹn? Ẹmi Mimọ Ọlọrun ni akasọ naa lati sọ ohun ti a ni fun wa.

94 Wo o, ogun ini kan. Ah ah! Iru Ogun ini wo ni?

…..nigbati a ti yan wa tẹlẹ, gẹgẹbi ipinnu Ẹniti nsiṣẹ ohun gbogbo gẹgẹbi idunnu ifẹ Rẹ.

Nigba ti o wa ni oun nikan, ki oun to di Baba, ki oun to di Ọlọrun, ki oun to di Olugbala, ki oun to di Oluwosan, ki o to di gbogbo nkan wọnyi, O ti yanwa tẹlẹ, O si kọ orukọ wa sinu Iwe Iye ti Ọdọ-Aguntan, O wo ohun gbogbo nipa imọtẹlẹ Rẹ, o si ri Orukọ rẹ, o si kọ ọ sibẹ pẹlu. Kin si ni? Nigba ti o ṣe, a wa si aye, a bi wa lati inu awọn obi to jẹ ẹlẹṣẹ, a si rin kiri aye, ki o to mọ ohun to ṣẹlẹ, ohun kan pe ọ pe, “Wa, wa, wa, nibi”.

Iwọ wipe, “Ah, Abba, Baba!”

A si bẹrẹ si wa. O ti yanwa tẹlẹ si ogun ini kan ninu Rẹ, ti a ti yantẹlẹ si wa. A ti jogun rẹ ṣaaju ipilẹṣẹ aye. Ah! Fun erongba ti ara Rẹ, lati siṣẹ ifẹ inu Rẹ. Bẹẹ ni gẹgẹ, lati jẹ Ọlọrun ati Olugbala.

95 Ninu Ẹniti ẹyin pẹlu, nigbati ẹyin ti gbọ Ọrọ otitọ ni, ihinrere igbala yin,…..

Ta si ni otitọ? Jesu ni otitọ, oun ni otitọ ihinrere. Ihinrere wo ni? Ihinrere kan ṣoṣo ni o wa, Galatia 1 wipe “Bi o ṣe angẹli kan ni o ba waasu ihinrere miran, jẹ ki o di ẹni ifibu. Eyi ni ihinrere igbala rẹ; ko si omiran. Ko si orukọ miran ti a fifun ni labẹ ọrun, nipa eyiti a le gba wa la” Bikoṣe orukọ wo? (Apejọpọ wipe, “Jesu Kristi, Oluwa”) Ah, ah! Ah!

Ninu Ẹniti, lẹyin ti ẹ ti gbagbọ, a fi edidi di yin.

Ah, "lẹyin ti ẹ gbagbọ" Bawo ni a ṣe lee fi oju fo iyẹn, ẹyin ara? Jẹ ki a fi silẹ di alẹ yii, tabi kin ni ẹ sọ? Emi ko lee tẹsiwaju nisisiyi. Jẹ ki a fi di alẹ yii. Emi ko sa lee fi Ọrọ yẹn silẹ "Edidi," Ewo ni iwọ ṣe lee de ibẹ.

96 Ogun ini nipa iyantẹlẹ. Mo jogun ohun kan. Kin ni ogun ini naa? Ẹnikan nilati fi dukia kan silẹ fun mi lati jogun. Iwọ wipe, "Jesu fi ogun ini kan silẹ fun ọ." Rara o, Jesu ko fi ogun kan silẹ fun mi, Jesu ko fi ogun ini kan silẹ fun ọ. Oun kan sọkalẹ wa, o sanwo Irapada rẹ, o si mu ọ pada si ogun ini rẹ. Sugbọn a ti kọ orukọ rẹ sinu Iwe Iye ti Ọdọ-aguntan ṣaaju ipilẹṣẹ aye. Ọlọrun ni o fun ọ ni Ogun ini rẹ. Ogun ini rẹ lo ṣaaju. Bi wọn ṣe gbiyanju lati jẹ ki o ri niyi: Ọlọrun wipe, "Ọpọ eniyan ni o ti ṣegbe, mo si fẹ ki o gba wọn la. Nitori naa, Emi yoo ran Jesu lọ, boya, awọn kan yoo kaanu Rẹ, wọn yoo si ri ohun ti mo ṣe lati gba wọn la." Ah, ah! Saanu mi! Emi ko lee ṣe iṣẹ ile-iṣẹ mi bẹyẹn - pẹlu bi mo jẹ alai-nimọ-to, Gene. Emi ko lee ṣe e bẹyẹn. Melomelo ni Ọlọrun?

97 Ọlọrun, nipa imọtẹlẹ Rẹ, ti mọ ẹniti yoo ni igbala ati ẹniti ki yoo ri igbala. O ran Jesu lati gba awọn ti O ti yan. Ṣe Paulu, ni ẹsẹ marun ṣaaju eleyi, ko sọ wipe, Oun ti yan wa ninu Rẹ ki aye to wa? Ogun ini wa niyẹn. Ọlọrun yan wa, o si jẹ ki Jesu wa sanwo itanran wa. Kin ni? Tita ẹjẹ silẹ, ki a ma ba a ka ẹṣẹ kankan si wa lọrun. Ko si ohun ti iwọ ṣe lati yẹ.

"Ẹniti o ba mọ-ọn-mọ dẹṣẹ, lẹyin igbati o ti ni imọ otitọ, ko si ẹbọ fun ẹṣẹ mọ"

Bayi, ibiti iwọ lee ri niyi, ki o wipe, "Iyẹn nkọ, Arakunrin Branham"

Sugbọn, saa ranti wipe, "awọn ti o ti gba imọ otitọ." Wọn ko gba otitọ: Wọn ni imọ otitọ, wọn ko gba otitọ. Ko ṣeeṣe, fun awọn ti a ti ṣi loju, ti wọn si jẹ alabapin Ẹmi Mimọ, ti wọn si ti ni itọwo agbara Ọrọ rere. O Jẹ awọn onigbagbọ aala lẹyin lọhun. Ọpọlọpọ lo ti kọwe si mi nipa iyẹn.

98 Awọn onigbagbọ aala yẹn wa sunmọ igbagbọ gan ni. Joshua ati Kalẹbu si wọ ilẹ naa. Tori kinni? Bayi a o pe ilẹ naa ni Ẹmi-Mimọ. Nibẹ ni ileri naa wa. Wọn wipe, "Ẹ ran awọn ami mejila lọ, ọkan lati inu ẹya kọọkan, ki a lee mọ ohun ti ogun ini wa jẹ, nibi ti a o jogun nibẹ. Nitori naa mo ran awọn ami lọ".

Gbogbo wọn de ilẹ naa, wọn si wipe, "Ah ah! Wọn yoo pe wa ni awọn gbarayilẹ mimọ! Awa ko le e ṣe iyẹn" Ṣe o ri i.

Joshua ati Kalẹbu wipe, "Emi yoo ri ohun ti o jẹ." Nitori naa, wọn wọ ilẹ naa wọn si wo o kaakiri. Wọn gé òsùsù eso girepu kan, wọn si pada wa. Wọn wipe, "Ẹyin ara, ilẹ yẹn dara pupọ! Ẹ wo eso ilẹ naa, ẹ tọ ọ wo."

Ohun ti awọn mẹwa sọ niyi, "Ah ilẹ yẹn dara, Sugbọn, a ko lee gba ilẹ naa. A ko lee duro lodi si gbogbo awọn ijọ-ẹgbẹ-nla-yẹn. O se ni laanu pe, a ko lee ṣee. Rara. Ko si ọna lati ṣe iyẹn". Wọn si bẹrẹ si sọ wipe, "Ah, ẹ jẹ ki a pada si Ejipti, si awọn ikoko alubọsa Ijipti. O san ki a pada sibẹ. A ko lee ṣe eleyi, ọna yii ti ha ju fun wa. A ko lee ṣe e".

99 Kalẹbu atijọ na wipe, "Ẹ duro jẹ, gbogbo yin!"

Joshua wipe, "Ẹ panu mọ, gbogbo yin! Ẹ jẹ ki nsọrọ".

Awọn mẹwa wipe, "Áh, àh, a ko le e ṣe! Bi mo ba nilati dẹkun apejẹ ti a ti nta tẹtẹ, Arakurin Branham. Bi mo ba nilati fi irun mi silẹ ki o gun bi i ti iya arugbo kan, emi ko ro pe, iyẹn yoo ṣeeṣe. Bi mo ba nilati dẹkun wiwọ sokoto penpe. Bi mo ba nilati dẹkun siga mimu! Iwọ ẹni are yii. Bẹẹ ni, "Iwọ ko lee ṣe".

Joshua wipe, Ah, o dara. Halleluyah! A le gba a "Kin ni? Wọn nwo awọn ilu nla nla, ti a fi odi yika. Joshua ati Kalẹbu nwo ileri ti Ọlọrun ṣe. Duro ti Ọrọ naa, ẹniti o wu ki iwọ jẹ. Duro ti ọrọ naa!

100 Peteru wipe, "Ronupiwada, olukuluku yin ki a si baptisi yin ni orukọ Jesu Kristi fun imukuro ẹṣẹ yin, nitori ileri naa wa fun yin. (Ilẹ ileri wo?) ati si awọn ọmọ yin, ati si awọn to wa ni ọna jijin rere, ani si iye awọn ti Oluwa Ọlọrun wa yoo pe"

Má jẹ ki eleyi bi ọ ninu (mo npari) Jọwọ ma jẹ ko bi ọ ninu. Ẹyin Ijọ Atipo Iwa Mimọ (Pilgrim Holiness) ati ẹyin Nasarinni, ẹ wa sinu isọdi-mimọ, ẹ si wa sibi ti ẹ ti ri awọn eso ilẹ naa, ẹ si yiju pada sẹyin. Ṣe ẹ ri ohun to ṣẹlẹ? Ohun to ṣẹlẹ niyẹn. Ẹ ti kọkọ wọ inu ilẹ naa. Fi ọmọ Ijọ Atipo iwa Mimọ, tabi Nasarinni kan ti o wa ninu ilẹ naa loni han mi, ti o nṣe isọji iwosan lailoogun, pẹlu iṣẹ ami ati iṣẹ ara. Fi ọkan han mi. Ẹ ti joko kalẹ pẹlu Ijipti, ẹ ti pada si awọn ikoko alubọsa. Ẹ pada ni Kadẹsi-bania. Otitọ niyẹn.

101 Kiyesi, jẹ ki nfun ọ ni ibikan ninu Heberu ori kẹfa. "Nitori ko ṣeeṣe, fun awọn ti a ti ṣi loju (Ẹ mọ otitọ, bi o ko ba mọ tẹlẹ, o ti mọ ọn nisisiyi.) ti wọn si ti jẹ alabapin, ti wọn si ti tọ ẹbun Ọrun wo".

Wọn tọ ọ wo. Awọn eniyan nlọ sile isin, wọn joko, wọn si wipe, "Ṣe o mọ wipe, o le jẹ otitọ ni wọn nsọ. O ṣeeṣe ko ri bẹẹ, sugbọn mo sọ fun ọ, yoo gba ọpọ igbagbọ lati ṣe iyẹn".

Wọn ti tọ ẹbun ọrun wo, wọn si ti ka ẹjẹ majẹmu naa si ohun aimọ, ti a fi sọ wọn di mimọ“.

Gẹgẹbi oniwaasu kan. O wipe, “Mo ni ipe lati jẹ iranṣẹ Oluwa” Iya rẹ si ran lọ sile Iwe ẹkọ Bibeli.

Iya wipe, “Ohun ti emi yoo ṣe nipe, n o ṣe iṣẹ agbafọ aṣọ. Emi yoo ran ọ lọ kọ ẹkọ”. Asiṣe to buru julọ ti Iya yii si ṣe niyẹn. Bẹẹ ni. Wọn yoo mu gbogbo ohun ti Ọlọrun ti fi sinu rẹ kuro.

102 Kiyesi bayi.

Nitori bi a ba mọ-ọn-mọ dẹṣẹ, lẹyin igbati a ti gba imọ otitọ. Imọ naa - o ri i ninu Iwe Mimọ, o si mọ pe Iwe Mimọ sọ pe, Oun jẹ ọkan naa, lana, loni ati titi lae lae - ori i wipe, imọ otitọ ni o ri yẹn, o si yi kuro, o si ka ẹjẹ Majẹmu naa. Bi ohun aimọ….

Ọkunrin kan wipe. “Bẹẹ ni, mo gba Ọlọrun gbọ”. O dara, o gbe igbesẹ akọkọ.

“Bẹẹni, mo gbagbo ninu isọdimimọ.” Bẹẹni, iwọ wa ni aala ilẹ naa, o ti sunmọ pupọ lati gba Ẹmi Mimọ. Sugbọn iwọ wo yika, o si wipe, 'Emi ko mọ nipa iyẹn. Bi mo ba ni lati ṣe bi awọn wọnyẹn, ko da mi loju. Ṣe o mọ orukọ ti wọn npe wọn? Ko da mi loju pe mo le e ṣe iyẹn. Rara, emi yoo lọ darapọ mọ awọn miran“.

O mọ ohun to ṣẹlẹ? O wipe ko ṣeeṣe fun wọn lati wọle. Wọn ti dẹṣẹ rekọja Oore-ọfẹ, Bibeli sọ bẹẹ. Mo mọ pe iyẹn le pupọ. Sugbọn Bibeli wipe, Wọn ti tọ ẹbun Ọrun wo, wọn ti ka ẹjẹ majẹmu ti a fi fọ wọn mọ si ohun aimọ“.

103 Wọn wipe, “Mo gbagbọ ninu isọ-di-Mimọ, igbe aye mimọ”. Dajudaju, sugbọn nigbati o ba ri otitọ ti ibaptisimu Ẹmi Mimọ, ati awọn nkan wọnyi ninu Bibeli, iwọ si ti ṣe kin ni? Iwọ ti ka ẹjẹ Majẹmu ti a fi wẹ ọ mọ ni ohun aimọ. Kin ni o mu ọ de ipo isọdimimọ? Kin ni o ya ọ kuro ni ipo ẹlẹṣẹ? Kin ni o mu ẹṣẹ kuro laye rẹ. Ti o mu siga mimu, agbere, ati awọn ohun ti ko tọ kuro. Kin ni o ṣe iyẹn? Ẹjẹ ti Majẹmu naa! Nigba naa, iwọ ti wa si tosi to lati tọ girepu ilẹ naa wo, iwọ si wa tiju ihinrere? O nbẹru ijọ ẹlẹkọ adamọ rẹ? Ki Ọlọrun saanu fun wa! Bẹẹ ni, sa. O ti ka ẹjẹ Majẹmu naa si ohun aimọ, o si ti kẹgan iṣẹ oore ọfẹ. Ko ṣeeṣe fun un lati wọ ilẹ naa titi lae“.

104 Kin ni o ṣẹlẹ? Mo beere lọwọ rẹ. Bayi, mo jẹ alafiwe, ẹnikẹni ti o ba si mọ Bibeli yoo jẹ alafiwe. Njẹ eyikeyi ninu awọn eniyan yẹn wọ ilẹ ileri? Ko si ọkan ninu wọn. Awọn wo ni o wọ ilẹ naa?“ Awọn ti o lọ ni iṣaaju, ti wọn si wipe, ”A lee gba ilẹ naa“.

A lee ni Ẹmi Mimọ nitori pe, Ọlọrun sọ bẹẹ! Peteru sọ ni ọjọ Pẹntikọsti pe, bi emi ba ronupiwada, ti mo si ṣe itẹbọmi ni orukọ Jesu Kristi emi yoo gba Ẹmi Mimọ, nitori ileri naa wa fun mi. Mo nifẹ lati ṣe e. Ileri naa si jẹ temi“ Ṣe o ye ọ? Bayi, ileri naa jẹ temi. Mo gba a. Temi ni! Dajudaju, bẹẹ ni. Awọn nikan ni o wọ ilẹ naa.

Ah, Iwọ wipe, 'Sugbọn Arakunrin Branham nigba ajinde nkọ?“ Wọn ko ni si nibẹ. O wipe ”Ah, wọn ko ni si nibẹ? Rara sa.

105 Wọn wipe, “Iwọ ngbe ara rẹ ga bi ti Mose, Iwọ siwi pe o ti ri Abrahamu? Abrahamu si ti ku tipẹ, iwọ ko ti I pe aadọta ọdun, o si ti ri Abrahamu?”

O wipe, “Kin Abrahamu to wa, EMI NI.” Ah, ah ah! EMI NI naa, Ẹniti o wa nigbagbogbo, Ọlọrun ainipẹkun. Kii ṣe ti ana tabi ti ọla; EMI NI. “Ọlọrun to wa ni gbogbo igba, Elohimi, EMI NI. Nigbanaa wọn mu OKUTA Wọn fẹ pa a.

Wọn wipe, “Awọn baba wa jẹ mana ninu aginju fun ogoji ọdun. Ọlọrun rọjo onjẹ silẹ lati ọrun, o si bọ wọn. Wọn lọ silẹ isin, wọn si jẹ ọmọ ijọ to dara fun ogoji ọdun. (Iya mi to dara yẹn, mi ijọ yii ni o ti ku ”ati ohun bi iwọn yẹn) Baba wa jẹ Mana ni aginju fun ogoji ọdun.

Jesu wi pe, “Gbogbo wọn ni osi ku. (Iku tumọ si iyapa ainipẹkun”) Gbogbo wọn ni o ku. Sugbọn Emi sọ fun yin pe, “Emi ni onjẹ iye ti o ti Ọrun Sọkale wa, bi ẹnikan ba jẹ ounjẹ Ẹmi yii, yoo ni Iye ainipẹkun oun ko si lee ṣegbe. Emi yoo si ji dide ni opin ọjọ” Ah, arakunrin, njẹ kii ṣe iyanu bi?

Njẹ Oun kii ṣe Iyanu bi?

Ṣe Jesu Oluwa kii ṣe Iyanu?

Oju ti ri, eti gbọ, ohun ti a kọ sinu Ọrọ Ọlọrun

Ṣe Jesu Oluwa wa kii ṣe Iyanu.

106 Ṣe bẹẹni? A ri Ẹmi, onmọ Rẹ laarin wa. A ri I ti o nṣe iṣẹ iyanu, iṣẹ ami ati iṣẹ ara. A ri I ti a kọ ọ silẹ sinu Ọrọ Rẹ nihin, a si rii, ti a fẹsẹ rẹ mulẹ. Ah, ah!

Oju ti ri, ẹti ti gbọ

Ohun ti a kọ sinu Ọrọ Ọlọrun

Jesu Oluwa ko jẹ iyanu bi?

107 Ni iṣẹju meji tabi mẹta si, a o ni isin itẹbomi nibi yi. Awọn ti a o ṣe itẹbọmi fun, jẹ ki awọn obinrin lọ si apa ibi, ki awọn ọkunrin si lọ si apa keji. Awọn obinrin ni apa ibi yii. Awọn arabinrin yoo wa nibẹ pẹlu aṣọ ati paarọ. Bi a ba ri ọkunrin tabi obinrin kan ni bi lowurọ yi ti o gbagbọ pe Ọrọ Ọlọrun niyi, iwọ si gbagbọ pe, Ọlọrun npa ileri Rẹ mọ. Pe, bi ẹnikan ba ronupiwada tọkan-tọkan awọn ẹṣẹ rẹ.

Bayi ẹjẹ naa ko ti i ṣe ohunkohun sibẹ. Rara, ki ki igbagbọ rẹ ninu Ọlọrun sin pe ọ pe, ki o wa. Ohun to nṣẹlẹ niyẹn bayi. O npe ọ. O wipe, “A ko tii baptisi mi” O npe ọ. O wipe, “Bi moba sa lee bẹrẹ nibikan” O npe ọ. O wipe, “Bi mọ basa lee bẹrẹ nibikan” Ohun ni yẹn, bẹrẹ bayi. Lẹyin ti o ba bẹrẹ iwọ yoo le e ṣe dara si. Oni lati yipada, bẹrẹ.

O wipe, emi ko ti i ri i bẹyẹn ri“

108 O dara, arakunrin ọwọn, mo fẹ ki o fi ibi kan han mi ninu iwe Mimọ, ẹnikan ṣoṣo ti a baptisi yatọ si ni orukọ Jesu Kristi. Mo ti ṣe ipenija yii fun ọdun mọkan-le-lọgbọn iṣẹ iriju iwaasu mi kaakiri agbaye. Gbogbo ẹniti wọn ti ṣe itẹbọmi yatọ si orukọ Jesu ni wọn nilati yan itẹbọmi ṣe ni orukọ Rẹ.

Ọlọrun ni orukọ kan ṣoṣo, orukọ Rẹ ni Jesu. Eyi ni Ọmọ Rẹ. O gba Orukọ Baba Rẹ. O gba Orukọ Baba Rẹ. Jesu ara naa jẹ eniyan. A mọ iyẹn. Iyẹn ni ọmọ Ọlọrun, ti a siji bo. Bayi a ko gbagbọ ninu bi awọn onigbagbọ Ọlọrun jẹ ọkan bi ika ọwọ kanṣoṣo. A gbagbọ pe awọn ifarahan Ọlọrun mẹta ni o wa. Ipo iṣẹ mẹta Ọlọrun, ti O farahan ninu rẹ. Sugbọn Ọlọrun kan ni o wa. Otitọ niyẹn. A gbagbọ pe Ọlọrun ni ipo iṣẹ mẹta. O ni ipo iṣẹ kan laye, fun igba kan.

109 (Bayi ẹyin obinrin ẹ lọ si apa ibi yii, ki ẹyin ọkunrin lọ si apa ibẹ yẹn. Wọn si npese silẹ fun isin itẹbọmi bayi)

110 Bayi, Ọlọrun ni ipo-iṣẹ mẹta. Ọkan ninu rẹ ni Ọlọrun gẹgẹbi Baba tabi saa ti Ọlọrun Baba. Ekeji ni ipo-iṣẹ Ọmọ Ọlọrun, ẹkẹta si ni Ẹni Mimọ. Loni, ipo-iṣẹ wo ni Baba nsiṣẹ ninu Rẹ loni. (Apejọpọ sọ wipe, “Emi Mimọ) Emi Mimọ. Kin ni oun ni igba ti o kọja lọ. (”Jesu“) Jesu. Kin ni oun ni igbati o ṣaaju iyẹn (”Baba“). Sugbọn Ọlọrun kan naa ni. Ṣe bẹẹ ni? Oun ni Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ. Awọn ipo-iṣẹ mẹta ti Ọlọrun kan. Ọlọrun kan.

Sugbọn bayi, Baba kii ṣe orukọ. Ṣe bẹẹ ni? Mo fẹ beere lọwọ rẹ. Nisisiyi mo fẹ fun ọ ni Matiu 28:19, nibiti Jesu ti wipe. “Ẹ ma a lọ, ki ẹ maa kọ orilẹ-ede gbogbo, ẹ baptisi wọn ni orukọ ti Baba.

111 Bayi mo fẹ bi ẹ ti mọ Iwe Mimọ to, sọ fun mi ni igbati moba yẹ kuro ninu rẹ. O si wi fun wọn pe. “Ẹ lọ si gbogbo agbaye, waasu ihinrere fun gbogbo ẹda. Ẹniti o ba gbagbọ, waasu ihinrere fun gbogbo ẹda. Ẹniti o ba gbagbọ, ti a si baptisti yoo la. A ki yoo da awọn ti o gbagbọ lẹbi. Ni orukọ mi wọn yoo le emi eṣu jade (ṣe otitọ niyẹn?) wọn yoo sọrọ ni ede titun, wọn yoo gbe ejo ni ọwọ” Bayi, emi yoo ṣe atunṣe Matiu fun yin.

Fetisilẹ bayi. Mo bere lọwọ onimọ itan aye kankan. Bayi eyi wa lori fọnran ti a gba silẹ, nitori naa, o nlọ si gbogbo agbaye. Mo fẹ ki onimọ itan aye kan wa fi iwe mimọ kan tabi, iwe itan kan ti o fi Kristẹni kan han ti wọn ṣe itẹbọmi fun ni orukọ Baba Ọmọ ati Ẹmi Mimọ ṣaaju igba ti Ijọ Katoliiki fi lọlẹ nibi ipade igbimọ ti Nikia. Bayi a ti gba iyẹn sori fọnran, o si nlọ ka gbogbo aye. Wọn nṣe ẹ̀dà rẹ si ede mẹtadinlogoji ọtọọtọ. Emi yoo sanwo ọkọ rẹ lati oke okun. Otitọ niyẹn.

Baba, Ọmọ, ati Ẹmi Mimọ jẹ ẹkọ iṣina, to jẹ panda, ti agbelẹrọ ijọ Katoliki, kii si ṣe itẹbọmi ti Kristẹni. Bẹẹ ni. Luther mu un jade lati inu ijọ Katoliki pelu ijẹwọ igbagbọ. Wesley pẹlu mu un lo. Sugbọn eyi ni ọjọ ifihan awọn ọmọ Ọlọrun nigbati awọn ijinlẹ to ti farasin lati ipilẹṣẹ aye yoo di mimọ. Wakati naa niyi. Dajudaju.

112 Ranti wipe, ko si ẹnikan ninu Bibeli ti a baptisi ni orukọ Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ. Fun ọọdunrun ọdun lẹyin iku aposteli to gbẹyin ko si ẹnikan ti a baptisi ni orukọ Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ. Mo ti ka “Awọn Baba igbagbọ to ṣaaju igbimọ Nikia”. Igbimọ Nikia. Nibẹ ni wọn si ti gbe ijọ-to-feniyan-ṣadari-dipo-Ẹmi Mimọ ti wọn pe ni Ijọ Kristẹni Agbalaaye, ti wọn si tipa eyi mu gbogbo eniyan sinu rẹ, wọn si pe e ni Ijọ Katoliiki, ọrọ yii gan, “Katoliiki ja si ”Gbogbo-gbo! Ijọ Gbogbo-gbo kan ni agbalaaye lati wa fun gbogbo Kristẹni aye.

Wọn fipa mu awọn eniyan darapọ mọ ọn. Nibẹ ni wọn paarọ oriṣa Fẹnọsi, wọn fi Maria dipo rẹ. Wọn mu oriṣa Jupiteri, wọn fi Peteru dipo rẹ. Ibọriṣa ni sibẹ. Ijọ Katoliki jade lati igbimọ yẹn.

113 Wọn ni ere itage kan to nlọ lọwọ bayi ni Louisville ti wọn pe ni Ben Hur. Wọn ni awọn ofin mẹwa ni igba kan. O wa ni ki wọn ṣe ọkan fun ẹgbẹrun kan abọ ọdun ti Akoko Okunkun Aye. O wu mi ki wọn ṣe iyẹn.

Ẹgbẹrun kan abọ ọdun ti wọn fi ṣe inunibini, nigbati wọn fi ipa mu gbogbo eniyan ti wọn si pa wọn. Wọn so ọwọ enikan mọ maluu kan, ati ọwọ keji mọ maluu keji. Wọn mu ki o fi ẹnu ko agbelebu tabi ki wọn le awọn maluu mejeji si ọtọọtọ. Mo ti fi ọwọ si ara opo ni Switzerland, nibiti wọn tige wọn ni ahọn, ti wọn pe wọn ni ajẹ. Otitọ niyẹn. Bẹẹ ni!

114 Ẹmi yẹn kan naa si wa loni. Ofin ni o kan ṣe idiwọ fun un. Duro di igbati yoo ni ominira rẹ. Bibeli sọ bẹẹ. Sa duro di igbati yoo fi awọ rẹ han ti o ni anfani lati sisẹ. O ṣeeṣe ki ẹ fi ibo gbe e wọle laipẹ. Yoo wa, yoo wa, ko si ọna ki o má wa. Otitọ niyẹn o nbọ wa. Nigba to ba si de, sa kiyesi. Sugbọn arakunrin, iwọ nilati mọ ohun kan yii: Mo mọ Ẹniti mo gbagbọ. Amin. Mo ntẹsiwaju taara. Oun niyẹn.

115 Igba kan wa ti mo sọ fun ẹni ti o kọ Bibeli Lamsa, nigbati o wo, ti o ri ami atijọ ti Ọlọrun yẹn, ti o jẹ awọn mẹta kekeke ninu rẹ. Mo wipe “Kin ni iwọnyẹn?”

O wipe, “Ọlọrun niyẹn ninu agbara mẹta”

Mo wipe, “Gẹgẹbi Baba, Ọmọ ati Ẹmi Mimọ.

O wo mi. O wipe, “Ṣe iwọ gba iyẹn gbọ?”

Mo wipe, “Bẹẹ ni sa”

O wipe, “Mo ri Imọ - nipa - Ẹmi yẹn ni alẹ ijẹlo. Mo roo wipe, iwọ jẹ wolii Oluwa.” O wipe, ki Ọlọrun bukun ọkan rẹ. O fi ọwọ rẹ gba mi mu, o wipe, Mo ti mọ nisisiyi pe, bẹẹ lori. Awọn eniyan Amẹrika yii ko tilẹ mọ ohunkohun. Wọn ngbiyanju lati mu iwe ti a kọ ni Ila oorun aye, ki wọn si loye rẹ pẹlu oye ti Iwọ oorun aye. Wọn ko tilẹ mọ Bibeli wọn. Ko si orukọ miran ti a fifun ni labẹ ọrun ko si orukọ miran, gbogbo awọn ti a baptisti ri, a baptisi wọn ni orukọ Jesu Kristi. Ko si ohun to njẹ, ẹni mẹta ninu Ọlọrun kan“. Iyẹn si ni ọmọwe Lamsa, olutunmọ Bibeli Lamsa ti i ṣe ọrẹ-mimu aarẹ Eisenhower, ati awọn aṣoju nla nla agbaye. O fi ọwọ rẹ gba ni mu, o wipe, ”Lọjọ kan, wọn yoo tàbọn lu ọ fun iyẹn. Sugbọn ranti pe gbogbo awọn eniyan yẹn ku fun afojusun kan.“

116 Mo fẹ ki o ri bi igbati Peteru atijọ naa joko ni inu tubu. Ọmọkunrin kekere kan wa nibẹ ti ara rẹ ko balẹ̀ rara, Peteru wipe “Kin ni o ṣe ọ?”

O dahun pe, “Ṣe iwọ mọ pe wọn yoo pa ọ?”

Peteru wipe, “Bẹẹ ni”

O wipe, “Loni ni ọjọ iku rẹ”

Peteru wipe, Bẹẹ ni“

O wipe. “Ṣe ẹru ko ba ọ ni?”

Peteru dahun pe “Rara”

O wipe, “O nilati jẹ ọkan ninu awọn Kristẹni ni ọ”

Peteru wipe, “Bẹẹ ni”

O wipe “kin ni o ṣẹlẹ?”

O si sọ fun un. O joko, o si sọ itan naa fun. Bi ọrọ naa ṣe tẹsiwaju, o wa, o wipe “Mo ti ni anfani lati gba ominira, ki n lọ ni Alafia lowurọ yii. Mo ti lee lọ darapọ mọ awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ ki n si wa laaye, ṣe o rii. Emi iba ti ni ominira. Sugbọn nigbati mo n lọ si ẹnu odi ilu, mo ri Ẹnikan ti nbọ wa, ti o wọle. Mo mọ Ẹniti oun iṣe. Mo wipe, Oluwa nibo ni iwọ nlọ?” O wipe “Mo pada wa ki a le kan mi mọ agbelebu nigba keji,” Peteru wipe Mo pada wa lẹsẹkẹsẹ.

Lẹsẹ kan naa, wọn wipe “Tani o njẹ ”Simoni Peteru?

O wipe “Emi ni yi”.

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu
William Marrion Branham
"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7